**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA (NOUN)**

# YOR 332
# Stylistics I
# (ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ KÌÍNÍ)

**FÁLADÉ, MONÍSỌ́LÁ RÓNKẸ́**
**B.A. Ed (ACE, ONDO) M.A. Ph.D (ÌBÀDÀN)**

**Department of Linguistics and African Languages**
**University of Ibadan,**
**Ibadan, Nigeria.**

**Course Code:** YOR 332

**Course Title:** Yorùbá Stylistics I (Ìmọ̀ Ìsọwọ́lo-Èdè Kìíní)

**Course Content:** Specifications (Course Description)

Introduction to Yorùbá stylistics with emphasis on the definition, theories, developments and relationship with linguistics and literature and currents trends in Yorùbá literary studies.

**Course Writer:** Dr. Fáladé, Monísọ́lá Rónkẹ́

**Course Editor:** Professor Adéṣọlá Ọlátẹ́jú

## ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ

Àkọ́lé Iṣẹ́ i

Vice Chancellor's Message ii

Àkóónú iii

Ìfáàrà sí kọ́ọ̀sì yìí vi

Àfojúsùn kọ́ọ̀sì yìí vii

Ojúṣe Akẹ́kọ̀ọ́ viii

Ìgbéléwọ̀n Akẹ́kọ̀ọ́ ix

Ìgbéléwọ̀n tí Olùkọ́ yóò Máàkì ix

Ìdánwò Àṣekágbá x

Ìlànà Máàkì Gbígbà xi

**MÓDÙ KÌN-ÍN-NÍ: ORÍKÌ, ÌDÀGBÀSÓKÈ ÀTI ÌṢÒRO TÓ KOJÚ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ**

Ìpín kìíní: Oríkì Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè 1

1.0 Ìfáárà 1

2.0 Èròńgbà àti Àfojúsùn 1

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú 1

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ 2

4.1 Orikì Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè 2

4.2 Ìpín Kejì: Ìdàgbàsókè Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè Yorùbá 4

4.3 Ìpín Kẹ́ta: Ìṣòro Tó Dojúkọ Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè Yorùbá 6

4.4 Ìpín Kẹ́rin: Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè Yorùbá Lóde Òní 8

5.0 Ìsọníṣókí 9

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe 10

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí 10

**MÓDÙ KEJÌ: ÀWỌN ẸKA ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ, AFỌ̀ ÀTI ÀWỌN OKÙNFÀ ÌYÀTỌ̀ INÚ AFỌ̀**


Ìpín kìíní: Àwọn Ẹka Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè 11

1.0 Ìfáàrà 11

2.0 Èròngbà àti Àfojúsùn 11

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú 11

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ 12

Ìpín kìíní: 12

4.1 Àwọn Ẹka Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè 12

4.1.1 Ìmọ̀ Ẹdá-Èdè 12

4.1.2 Lítíréṣọ̀ 13

4.1.3 Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè 14

4.2 Ìpín Kejì: Ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín àwọn ìmọ̀ yìí. 14

4.3 Ìpín Kẹ́ta: Kín ni Afọ̀? 15

4.4 Ìpín Kẹ́rin: Àwọn Okùnfà Ìyàtọ̀ Inú Afọ̀ 15

4.4.1 Ọ̀gangan-Ìṣẹ̀lẹ̀ 16

4.4.2 Orí Ọ̀rọ̀ Àpèjúwe 16

4.4.3 Ìmọ̀sílára Aṣàpèjúwe 17

4.4.4 Iṣẹ́ Afọ̀ 19

4.4.5 Ìsọníṣókí 19

5.0 Ìpín Karùn-ún: Rírán Èdè Níṣẹ́ 20

5.1 Rírán Èdè Níṣẹ́ 20

5.1.1 Èdè Ojoojúmọ́ 21

5.1.2 Èdè Iṣẹ́ Ọnà Aláwòmọ́ Lítíréṣọ̀ 22

5.1.3 Ìsọ̀rí Olóòró àti Oníbùú 22

6.0 Ìsọníṣókí 22

7.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe 23

8.0 Ìwé Ìtọ́kasí 23

**MÓDÙ KẸTA: ÀYẸ̀WÒ DÍẸ̀ LÁRA TÍỌ́RÌ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ ÀTI ÀWỌN ÀBÙDÁ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ**


Ìpín kìíní: Tíọ́rì Èdè Ojoojúmọ́ 24

1.0 Ìfáàrà 24

2.0 Èròngbà àti Àfojúsùn 24

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú 24

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ 25

4.1 Èdè Ojoojúmọ́ 25

5.0 Ìpín Kejì: Tíọ́rì Èdè Ewì 26

5.1 Èdè Ewì 26

6.0 Ìpín Kẹ́ta: Ìbáṣepọ̀ láàárín Èdè ojoojúmọ̀ àti Èdè Ewì 26

7.0 Ìpín Kẹ́rin: Ìyapa Èdè Ojoojúmọ́ àti Èdè Ewì 27

7.1 Ìyàpa Èdè Ojoojúmọ́ àti Èdè Ewì 27

7.1.1 Ìyapa Oníròó 27

7.1.2 Ìyapa Ẹlẹ́yọ Ọ̀rọ̀ 28

7.1.3 Ìyapa Onígírámà 29

7.1.4 Ìyapa onítumọ̀ 30

8.0 Ìpín Karùn-ún: Àwọn Àbùdá ọnà Ìṣọwọ́lo-Èdè 32

8.1 Àbùdá ọnà Ìṣọwọ́lò-èdè 32

8.2 Àwítúnwí 33

8.3 Ìbádọ́gba Gbólóhùn 41

8.4 Ìfọ̀rọ̀dárà 42

8.5 Àfiwé 44

8.6 Ìsohundènìyàn 45

8.7 Àsọrégèé 45

8.8 Àjùmọ̀rìn Ọ̀rọ̀ 46

9.0 Ìsọníṣókí 40

10.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe 48

11.0 Ìwé Ìtọ́kasí 49

## ÌFÁÀRÀ SÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Orúkọ kọ́ọ̀sì yí ni ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ KÌÍNÍ (STYLISTICS I) Ó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn iṣẹ́ tí o ó ṣe láti gba oyè ìjìnlẹ̀ àkọ́kọ́ nínú èdè Yorùbá. Ìdá méjì ni ó kó nínú àpapọ̀ àwọn kọ́ọ̀sì yóòkù tí o máa ṣe.

Bí ìmọ̀ yìí ṣe jẹ́ ṣẹ̀ṣẹ̀dé láàárín àwọn ìmọ̀ yòókù, síbẹ̀ ó ní ìlànà tó gbóúnjẹ fẹ́gbẹ́ tó sì tún gbàwo bọ̀ nínú àyẹ̀wò lítíréṣọ̀. Kọ́ọ̀sì yìí yóò jẹ́ kí o gbáradì láti ní òye nípa ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àlàyé àti ìgbéléwọ̀n fún iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ èyíkéyìí. Lára àwọn ohun tí ìwọ yóò kà nínú kọ́ọ̀sì yí ni bí iṣu ìmọ̀ yí ṣe kú àti bí ọ̀bẹ ṣe bẹ́ ẹ́, ìyẹn ni pé a ó wo orírun orúkọ tí a pa láró fún ìmọ̀ yí àti oríkì tí àwọn onímọ̀ fún un. Bákan náà, a ó wo àwọn ìṣòro tí ó dojúkọ ìmọ̀ yí àti ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrín ìmọ̀ yí àti àwọn ìmọ̀ méjì tó jẹ́ ẹ̀ka rẹ̀, ìyẹn ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀.

Lẹ́yìn èyí ni a ó wo bí o ṣe ń dàgbà sókè nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà irú èyí tó wù kó jẹ́ àti àwọn àbùdá ìmọ́ ìṣọwọ́lo-èdè nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá.

**Àfojúsùn Kọ̀ọ̀sì Yìí**

Àfojúsùn kọ̀ọ̀sì yi ni pé, yóò sọ ọ́ di ojúlówó akẹ́kọ̀ọ́ èdè Yorùbá tó dáńgájíá láti le è ṣe ìtúpalẹ̀, àlàyé àti ìgbéléwọ̀n fún iṣẹ́ ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀ èyíkéyìí, o ò ní dàbí òpè tí ó bá di ibi iṣẹ́ gbẹ́nugbẹ́nu. Lẹ́yìn tí o bá ti parí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó lè ṣe ọ̀rínkinwín àlàyé lórí bí ìmọ̀ yí ṣe dìde, oríkì tí a pa láró fun, ìbáṣepọ̀ tí ó ní pẹ̀lú àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ yòókù, àwọn tíọ́rì tí ó jẹ mọ́ ìmọ̀ yí àti àwọn àbùdá ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè Yorùbá.

A pín ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí sí Módù Mẹ́ta, lẹ́yìn èyí, a tún gbìyànjú láti ṣe àtúnpín fún Módù Kọ̀ọ̀kan kí èròǹgbà kọ́ọ̀sì yí lè jọ. Módù kìíní pín sí ìsọ̀rí mẹ́rin, níbẹ̀ ni a ti jíròrò lórí orírun àti oríkì rẹ̀ bí àwọn lámèyítọ́ ti gbé e kalẹ̀ ní ọ̀kan-ò-jọ̀kan àti èrò tiwa lórí rẹ̀. Lára àwọn ohun tí ó jẹ́ àkóónú módù kìíní ni bí ìmọ̀ yí ṣe ń dàgbà sókè nínú ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ èdè Yorùbá àti àwọn ìṣòro tí o dojú kọ ọ́. A ṣe àgbéyẹ̀wò ipò tí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè wà nínú ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ èdè Yorùbá lóde òní, ìyẹn bí a ṣe lè lo ìmọ̀ yí láti fi ṣe ìtúpalẹ̀ fún iṣẹ́ ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀ èyíkéyìí.

Módù kéjì pín sí ìsọ̀rí márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, ni ìpín kìíní ni a ti ṣàlàyé àwọn ẹ̀ka tí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ní ìyẹn ìmọ̀ ẹ̀dá èdè àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀. Ìpín kejì sọ̀rọ̀ lórí ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè àti àwọn ẹ̀ka méjèèjì yókù. Ìpín kẹ́ta àti kẹ́rin ni a ti jíròrò lórí afọ̀ àti àwọn ohun tí ó lè fa ìyàtọ̀ nínú afọ̀. Ìpín kàrún-ún tó parí módù yìí  ni a tí jíròrò nípa bí a ṣe lè rán èdè níṣẹ́ láti fi gbé ọnà jáde. A ní ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè pín sí méjì, àwọn ni ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ojoojúmọ́ àti ìṣọwọ́lo-èdè iṣẹ́ ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀. Èdè ojoojúmọ́ lè gba gbẹ̀fẹ́ tàbí kí ó má gba gbẹ̀fẹ́, ohun tí ó jẹ èdè iṣẹ́ ọnà aláwomọ̀ lítíriéṣọ̀ lógún ni ẹwà nítorí náà kò gba gbẹ̀fẹ́. Ìṣewẹ̀kú tí ó wáyé nínú iṣẹ́ ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀ ni ó bí ìsọ̀rí olóòró àti oníbùú, èyí ni pé àjọṣepọ̀ ní láti wà láàárín ètò olóòró àti oníbùú

Módù kẹ́ta pín sí ìsọ̀rí márùn-ún. Ìpín kìíní àti kéjì ni a ti ṣe àyẹ́wò díẹ̀ lára tíọ́rì ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè, ìyẹ́n, tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì bí àwọn onímọ̀ kan ṣe là á kalẹ̀ àti èrò tiwa lórí èrò yí. Èdè ojoojúmọ́ jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún èdè ewì, wọ́n gbà pé inú ládugbó èdè ojoojúmọ́ ni èdè ewì tí ń bùwẹ̀ bùmu. Ṣùgbọ́n àwọn onímọ̀ míràn gbà pé èdè ewì dá wà lọ́tọ̀, nítorí o ń rú òfin gírámà èdè ojoojúmọ́. Ìpín kẹ́ta mẹ́nuba ìbáṣepọ̀ tí o wà láàárín èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì. Ní ìpín kẹ́rin ni a ti sọ̀rọ̀ lórí àwọn ọ̀nà tí èdè ewì ń gbà yapa sí èdè ojoojúmọ́. Lára àwọn ọ̀nà tí ìyapa fi wà ní ìyapa oníròó, ìyapa ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀, ìyapa onígírámà tàbí ìyapa onítumọ̀. Ìpín karùn-ún tí a fi kádìí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí jíròrò àwọn àbùdá/ọnà-èdè lọ́kan-ò-jọ̀kan. Lára àwọn tí a sọ̀rọ̀ lé lórí níbí yìí ni Àwítúnwí, ìbádọ́gba gbólóhùn, ìfọ̀rọ̀dárà, àsọrégèé, ìsohundènìyàn, àfiwé àti àdàpè.

**Ojúṣe Akẹ́kọ̀ọ́**

Kí ọ̀tún wẹ òsí kí òsì wẹ ọ̀tún ni ọwọ́ fi ń mọ, bí olùkọ́ ṣe ni ojúṣe tirẹ̀ láti la akẹ́kọ̀ọ́ lọ́yẹ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ ṣe ojúṣe tirẹ̀ kí ó lè ṣe àṣeyege nínú ẹ̀kọ́ rẹ̀. Módù mẹ́ta ni a pín ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí si, tí módù kọ̀ọ̀kan sí tún pín sí ìpín mélo kan. Akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ ri pé òun ka àpilẹ̀kọ yìí ní àkàtúnkà àti àwọn ìwé míràn tí a bá yàn fún ọ.

Bákan náà, o ní láti gbìyànjú láti dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó wà ní ìparí ẹ̀kọ́ kọ̀ọ̀kan, èyí yóò jẹ kí o mọ bí òye àwọn ohun tó o kà ṣe yé ọ sí.

Ó ṣe pàtàkì kí o rí i pé o ń ṣe iṣẹ́ àmúṣe ṣíṣe rẹ lóòrèkóòrè kí o sì dáa padà ní àkókò tí ó yẹ kí olùkọ́ lè ṣe ìgbéléwọ̀n rẹ̀. Ó jẹ́ dandan fún ọ láti ṣe ìdánwò ní ìparí kọ́ọ̀sì yìí.

Akẹ́kọ̀ọ́ tún gbọ́dọ̀ mọ pé òun ní láti darapọ̀ mọ ìfarakínrà pẹ̀lú olùkọ́ nínú ètò tí àwọn aláṣẹ fásitì bá yàn fún ìfarakínra tàbí kí o bá olùkọ́ sọ̀rọ̀ lórí ẹ̀rọ alàgbèéká tàbí ẹ̀rọ ayára bí àṣá.

Pẹ̀lú àwọn ẹ̀kọ́ tí a ti ṣàlàyé nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o yẹ́ kí o gbìyànjú láti máa ṣe ìtúpalẹ̀ àlàyé àti ìgbéléwọ̀n fún iṣẹ́ ọnà èyíkéyìí tí ó bá gbámú.

Lákòtán-án, rí i dájú pé èdè tí o fi dáhùn ìbéèrè rẹ dára nípa lílo àkọtọ́ Yorùbá, kí ìdáhùn rẹ ma bàá forí ṣánpọ́n tàbí kí ó mú pọ́n-na dání.

Tí ó bá tẹ̀lé àwọn ìmọ̀ràn òkè yìí, ìwọ náà yóò lè fọwọ́ sọ àyà láti ṣe ìdámọ̀ àwọn oríṣiríṣi ọnà-èdè Yorùbá, ìtúpalẹ̀ àbùdá àti àwọn àyọlò ní èdè Yorùbá.

**Ìgbéléwọ̀n Akẹ́kọ̀ọ́**

Oríṣi ọ̀nà méjì ni a ó gbà ṣe ìgbéléwọ̀n fún iṣẹ́ yí. Àkọ́kọ́ ni iṣẹ́ ṣiṣe tàbí iṣẹ́ àdáṣe tí ó kó ìdá ọgbọ̀n (30%) nínú Ọgọ́rùn-ún. Èkejì ni ìdánwò tí akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ ṣe lẹ́yìn tí ó bá ti gba ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tán. Eléyìí náà kó ìdá ààdọ́rin (70%) nínú Ọgọ́rùn-ún.

**Ìgbéléwọ̀n tí Olùkọ́ yóò Máàkì**

Módù mẹ́ta ni ó wà fún ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú àpilẹ̀kọ́ yíí, tí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sì ní ìbéèrè tàbí iṣe ṣíṣe, akẹ́kọ̀ọ́ ni láti wá ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè wọ̀nyí. Ó kéré tán akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ dáhùn ìbéèrè mẹ́ta lábẹ́ iṣẹ́ kọ̀ọ̀kan èyí tí yóò fi ṣowọ́ sí olùkọ láti máàkì.

O gbọ́dọ̀ ri dájú pé o fi iṣẹ́ ṣíṣe yí ránṣẹ́ sí olùkọ́ ṣaájú ọjọ́ tí a bá dá. Bí ìdí pàtàkì bá wà tí o kò le fi iṣẹ́ ṣíṣe rẹ ránṣẹ́, ó ní láti fi tó olùkọ́ létí, ẹni tí o lè pinnu láti sún ọjọ́ náà síwájú.

**Ìdánwò Àṣekágbá**

Èyí ni kòkárí ìdánwò tí o máa jóko ṣe lẹ́yìn tí gbogbo ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí bá parí. Àwọn aláṣẹ ilé ẹ̀kọ́ ní yóò kéde ọjọ́, àsìkò àti gbọ̀gàn tí ìdánwò yóò ti wáyé. Ìdá ààdọ́rin ni ìdánwò yìí yóò kó.

**Ìlànà Máàkì Gbígbà**

Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí jẹ́ atọ́nisọ́nà bí máàkì gbígbà yóò ṣe rí.

| **ÌGBÉLÉWỌ̀N** | **MÁÀKÌ** |
|---|---|
| Iṣẹ́ àmúṣe Módù 1-3 | Ogójì (30%) |
| Ìdánwò àṣekágbá | Àádọ́rin (70%) |
| Àpapọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%). |

## MÓDÙ KÌÍNÍ

## ORÍKÌ, ÌDÀGBÀSÓKÈ ÀTI Ì̀ṢÒRO TÓ DOJÚ KỌ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ

### *Ìpín Kìíní: Oríkì Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè*

### 1.0 Ìfáàrà

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìwọ yóò kà nípa oríkì tí àwọn onímọ̀ fún ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ní ìbámu pẹ̀lú ìhà tí ó kọ sí ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn, o ó tún kà nípa bí ó ṣe ń dàgbà sókè nínú ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ Yorùbá, àwọn ìṣòrò tí ó dojú kọ ọ́ àti ipò ti ì̀mọ̀ yìí wà lónìí.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà módù yìí ni láti jẹ́ kí o ní ìmọ̀ kíkún lórí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè

Lẹ́yìn tí ó bá ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yí tán, o ó le:

(1) mọ oríkì ìmọ̀ yìí

(2) ṣe àlàyé lórí orírun àti ìdàgbàsókè rẹ̀ nínú ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ Yorùbá.

(3) ṣe àlàyé lórí àwọn ìṣòro tí ó dojú kọ ọ́.

(4) ṣe ìdámọ̀ bí ìṣọwọ́lo-èdè ṣe ń jẹyọ nínú ìtakùrọ̀sọ tàbí ètò ìbáraẹ̀nìsọ̀rọ̀ ní àwùjọ Yorùbá lóde òní.

### 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

(1) Ṣe àlàyé ṣokí lórí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè Yorùbá.

(2) Ṣe àlàyé ṣókí lórí ìgbédìde ìmọ̀ yi nínú ẹ̀kọ́ ìjìnlẹ̀ Yorùbá.

(3) Kín ni o lè sọ nípa àléèbù àwọn orúkọ tí a kọ́kọ́ fun-un ní èdè Yorùbá.

(4) Ṣàlàyé mẹ́ta nínú àwọn ìṣòro tí o dojúkọ ọ́.

(5) ‘Òdú ni ìmọ̀ ìsọwọ́lo-èdè láwùjọ Yorùbá’. Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 *Oríkì*

Orúkọ ìmọ̀ yìí jẹyọ láti ara àkànpọ̀ orúkọ àwọn ìmọ̀ méjì tí ó jẹ́ orísun rẹ̀, ìyẹn ìmọ̀ *'style'* àti *'linguistics'* tí ó wá parapọ̀ jẹ *'stylistics'* (ìmọ̀ sítáì àti lìngúísíìkì) = Talítíìkì lẹ́yìn tí ìparójẹ tí wáyé. (style + linguistics = Stylistics)

A ṣe àkíyèsí pé ìjọra wà nínú orúkọ yìí pẹ̀lú àwọn ìmọ̀ méjì tí ó bí sáyé. Ṣẹ̀ṣẹ̀dé ni ìmọ̀ yìí, ó jẹ́ ọ̀nà mìíràn tí àwọn onímọ̀ kan nípa èdè gbé kalẹ̀ fún àlàyé, ìtúpalẹ̀ àti ìgbéléwọ̀n afọ̀káfọ̀, kí a lè rí àwọn àbùdá tí a fi hun èdè nínú afọ̀ bẹ́ẹ̀. Bí àwọn lámèyítọ́ ti pọ̀ tó, bẹ́ẹ̀ náà ní oríkì ìmọ̀ yìí ṣe pọ̀ tó. Oríkì tí onímọ̀ kọ̀ọ̀kan fún ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè wà ni ìbámu pẹ̀lú ìhà tí ó kọ sí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ọnímọ̀ yìí.

Bally (1909) ní ìmọ̀ yìí ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ìmọ̀sílára àti ṣíṣe àgbékalẹ̀ èdè àti afọ̀. Nínú èrò Hartman àti Stock (1973:223) wọ́n ní ó túmọ̀ sí ṣíṣe àmúlò ìmọ̀ nípa ẹ̀dá-èdè fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà. Ẹlòmíràn tí ó tún dá sí ọ̀rọ̀ yìí ni Turner G.W. (1973:22) tí ó gbà pé ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ni a lè pè ní àwòrán afẹ̀dèsọ́nà kan nítorí ìgbékalẹ̀ iṣẹ́ ń fi irú ènìyàn tí o ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ hàn. Síwájú síi, bí oníṣẹ́ ọnà ṣe lo èdè àti ọ̀nà tí ó gbà ṣe iṣẹ́ rẹ̀ ń fi àwòjíjì irú èèyàn tó jẹ́ hàn, títí tó fí kan ìwà àdámọ̀ àti àwọn nǹkan tó jẹ ẹ̀ lógún láàárín àwùjọ tó bí iṣẹ́ ọnà yẹn sáyé.

Wellek (1971:65) gbà pé ohunkóhun tí a bá lè fi inú rò nípa ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè, tàbí ìtúmọ̀ yówù tí a lè fun, àti ojú yówù tí a lè fi wò ó, ara ìmọ̀ ẹ̀dá èdè ló ti súyọ. Ó tẹ̀síwájú pé;

> Àwọn tó ń ronú nípa èdè àti lílò rẹ ni ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè jẹ lógún, ní pàtàkì, ohun tí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ń tẹpẹlẹ mọ́ ni pé báwo la ṣe ṣe ìgbékalẹ̀ lítíréṣọ̀ gan-an, irú èyí yówù kó jẹ́, tí ó yàtọ̀ sí ohun tí a gbékalẹ̀ gan an tí í ṣe lítíréṣọ̀.

Widdowson (1975:3) pè é ni fífi ojú ìwòye tàbi ìlànà ẹ̀dá-èdè ṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀. Nígbà tí Fowler (1981:24) ní ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè jẹ́ ṣíṣe àmúlò èrò, ọgbọ́n àti ìmọ̀ ẹ̀dá èdè fún ìṣàtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀. Èrò Ọlábọ̀dé (1981:50) kò fi gbogbo ara yàtọ̀ sí ti àwọn onímọ̀ ìṣaájú pẹ̀lú ojú ìwòye rẹ̀. Ó sọ pé ìbáṣepọ̀ tó lóòrìn wà láàárín ìmọ̀ ẹ̀dá èdè àti ìmọ̀ ìṣàtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀, èyí ló ṣokùnfà àbá tó dá pé oríṣi ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ló wà;

ìṣọwọ́lo-èdè onílànà lìngúísíìkì (linguistic stylistics) àti ìṣọwọ́lo-èdè tí kì í ṣe onílànà lìngúísíìkí ( literary stylistics).

Lójú Burton àti àwọn mìíràn (1974:124) wọn ní:

> A lè fi gbogbo ara gbà pé ìṣọwọ́-ṣe ti á ń pè ní (style) jẹ mọ́ abala kan nínú àyẹ̀wò, ìtọpinpin, ìtúpalẹ̀ àti ìgbéléwọ̀n iṣẹ́ ọnà, àmọ́ ṣa o, àwọn ìṣòro atinúhùnmọ̀ kan wá jẹyọ lóríṣiríṣi. Ẹ̀yí tó bẹ̀rẹ̀ láti ibi oríkì, ibi ti imọ̀ yí fara pamọ́ sí nínú iṣé ọnà, bí a ṣe lè sàlàyé àti àpèjúwe rẹ̀, ìye ẹ̀ka rẹ̀ tí a lè rí àti ìdí ti ìṣọwọ́-ṣe kan ṣe dára ju òmíràn lọ.

Lójú Burton àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀, ìmọ̀ yí kò rọrùn láti fún ní oríkì kan pàtó. Wọ́n gbà pé àjànàkú ìmọ́ yìí kọjá mo rí nǹkan fìrí. Nítorí náà, ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè jẹ́ ìmọ̀ tí a lè lò láti ṣe ọ̀rínkinwín àlàyé àti ìtúpalẹ̀ àwọn ọnà èdè tí o súyọ nínú lítíréṣọ̀ èyíkéyìí kí àwọn àbùdá àti bí oníṣẹ́ ọnà ṣe hun èdè bí ẹni hun ẹní nínú irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ lè fojú hàn dé.

## ÌPÍN KEJÌ

## ÌDÀGBÀSÓKÈ ẸKỌ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ YORÙBÁ

Àkíyèsí fi hàn pé ìmọ̀ yí ti wà láti nǹkan bí ọ̀rúndún kọkàndínlógún ọdún sẹ́yìn Enkivist (1973) ṣùgbọ́n tí kó sẹni to kọ ibi ara síi gẹ́gẹ́ bí ẹ̀kà ìmọ̀ tó lè dá dúró tí a lè ṣe àmúlò nínú àyẹ̀wò iṣẹ́ ọnà. *'Stylistics'* (tálítíìkì) kọ́kọ́ jẹyọ nínú ìwé àtúmọ̀ èdè, Oxford English Dictionary ní Ọdún 1882.

Nínú ìyànjú rẹ̀ láti ṣe àlàkalẹ̀ ohun tó yẹ kó jẹ́ pàtó oríkì ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè gẹ́gẹ́ bí ìrísí àti ìhùwàsí rẹ̀ nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà, Riffatere (1969:16) ló ta ni lólobó pé ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè, orúkọ yìí bí a ṣe mọ̀ ọ́n lédè gẹ̀ẹ́sì *'style'* jẹyọ láti inú ọ̀rọ̀ Greek kan *'stylus'* èyí ní wọ́n pa láró tí wọ́n sì ń pè ní *'style'* lédè gẹ̀ẹ́sì.

Ọ̀nà tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ń gbà ṣe nǹkan tí o jẹ àbùdá àdání ti ẹni náà ní tí o jẹ́ pé àbùdá yi yóò yàtọ̀ sí tí ẹlòmíràn ni ìṣọwọ́ṣe *(style/sítáì).* Ó tún jẹ òṣùwọn kan pàtàkì tí a máa ń lò láti fi mọ̀ pe ẹnìkan mọ ohun kan ṣe ju ẹlòmíràn lọ. Bí àpẹẹrẹ, ìṣọwọ́ṣe Táyé lè yàtọ̀ sí ti Kẹ́hìndé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọmọ ìyá kan náà ni wọ́n àti pé ọjọ́ kan ni a bí wọn. Ó fẹ́rẹ̀ má sí ohun kan tí kò ní sítáì. Bí àpẹẹrẹ, a rí sítáì tàbí ìsọwọ́ṣe irun, sítáì ọ̀rọ̀ sísọ, irun gígẹ̀ tàbí dìdì, sítáì ìwọsọ, sítáì ìrìn. Lọ́rọ̀ kan, gbogbo ohun tí a ń ṣe láye ni sítáì tàbí ìṣọwọ́ṣe wà fún. Ohun kan tàbí ìwà kan tí ẹnìkan ń ṣe lemọ́lemọ́ ní a lè pé ní ìṣọwọ́ṣe/sítáì irú ẹni bẹ́ẹ̀.

Tí a bá wá fi ojú yìí wo lítíréṣọ̀, a lè sọ nípa sítáì òǹkọ̀wé tàbí akéwì. Sítáì ti òǹkọ̀wé kan lè yàtọ̀ sí ti òmíràn. Bákan náà ni sítáì ẹ̀yà lítíréṣọ̀ tún yàtọ̀ síra wọn. Ìmọ̀ nípa *'style'* ni wọ́n ń pè ní *'Stylistics'* l'édè gẹ̀ẹ́sì tí a wá ń pè ní ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ní Yorùbá. Ìmọ̀ yí jẹ́ tuntun, ó ní àyè pàtàkì nínú ìtúpalẹ̀, àlàyé àti ìgbéléwọ̀n lítíréṣọ̀. Àwọn onímọ̀ tó bí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè sí àwùjọ iṣẹ́ ọnà ni ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti ọ̀rọ̀ lámèyítọ́ lórí lítíréṣọ̀. Ọ̀rínkiniwín èdè ló jẹ ìmọ̀ ẹ̀dá èdè lógún nígbà tí àyẹ̀wò àti ìtọpinpin lítíréṣọ̀ pẹ̀lú ojú lámèyítọ́ jẹ ọ̀rọ̀ lámèyítọ́ lórí lítíréṣọ̀ lógún tí wọ́n sì ń lo oríṣiríṣi tíọ́rì láti ṣe ìtúpalẹ̀ fún iṣẹ́ ọnà.

Ìràwọ̀ ìmọ̀ yí tàn jáde lẹ́yìn àgbéjáde ìwé tí Charles Bally, onímọ̀ ìsọwọ́lo-èdè ní Faranse, tí ó tún jẹ́ ọ̀kan lára akẹ́kọ̀ọ́ àwọn agbátẹrù tíọ́rì ìfojú-ìhun-wo lítíréṣọ̀ gbé jáde ni (1909) tí ó sì pè ní *'stylistique'*. Ìwé yìí tan ìmọ́lẹ̀ sí ohun tí ìmọ̀ *'stylistics' jẹ́.* Lẹ́yìn èyí ní ìmọ̀ yí di ìlú-mọ̀ọ́ká kárí ilẹ̀ Yuropu, (Europe) látàrí iṣẹ́ àwọn onímọ̀ bíì

Leo Spitzer àti àwọn mìíràn. 1960 ni ìmọ̀ yìí tàn kalẹ̀ ní orílẹ̀ Amẹ́ríkà àti Wales (1997:437).

Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè gẹ́gẹ́ bí ẹ̀ka ẹ̀kọ́ èdè Yorùbá bẹ̀rẹ̀ ní 1960 lábẹ́ ẹ̀ká ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀dá èdè àti èdè Nàìjíríà (Department of Linguistics and Nigerian Languages) tí o tí yi padà báyìí sí ẹ̀ká ìmọ̀ ẹ̀dá èdè àti èdè Áfíríkà (Linguistics and African Languages) gẹ́gẹ́ bí Bamgboṣe (1991) àti Ọlátúnjí (1993) ti ṣàlàyé. Ó jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀ka ẹ̀kọ́ márùn-ún tí wọn dá sílẹ̀ nínú ẹ̀ká èdè Yorùbá.

Àwọn tó ṣe agbátẹ̀rù ìmọ̀ yìí ṣàkíyèsí pé iṣẹ́ lámèyítọ́ iṣẹ́ ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀ sábà máa ń jẹ́ aṣègbè àti pé bí a ṣe ń lo èdè ní àsìkò kan, fún iṣẹ́ kan àti ní Ọ̀gángán ìṣẹ̀lẹ̀ kan máa ń yàtọ̀ sí ara wọn. Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè yí ní àǹfàní tó gbòòrò jù ṣíṣe àyẹ̀wò àti ìtọpinpin lítíréṣọ̀ pẹ̀lú ojú lámèyítọ́ lọ nítorí ó máa ń ṣe ìwádìí àti àwárí àwọn ẹ̀rí ìlò-èdè inú afọ̀káfọ̀ láti fi ìdí ìtúpalẹ̀ múlẹ̀. A tí rí lára àwọn onímọ̀ lédè Yorùbá tí wọ́n tí fi ìmọ̀ yìí ṣe àyẹ̀wò àti ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ lónìí. Lára wọ́n ni Yai (1976), Ọlábọ̀dé (1989), Ọlátẹ́jú (1998), Òjó (2013), Fákẹ́yẹ (2014), àti Fáladé (2021).

## *Ìpín Kẹ́ta*

## ÌṢORO TÍ Ó DOJÚKỌ ÌMỌ̀ YÌÍ

Ìṣòro mẹ́rin ló dojúkọ ìmọ̀ yìí, ìṣòro kìíní ni orúkọ tí wọn yóò fún un. Ìdásílẹ̀ ìmọ̀ ìsọwọ́lo-èdè láti ọwọ́ àwọn onímọ̀ méjèèjì, ìyẹn ìmọ̀ ẹ̀dá èdè àti ọ̀rọ̀ lámèyítọ́ lórí lítíréṣọ̀ tó dá a sílẹ̀ mú ìṣòro díẹ̀ lọ́wọ́ nípa orúkọ tí wọ́n yóò fún-un. Ìlànà méjì ni wọ́n fi lélẹ̀ tí orúkọ tí wọ́n fẹ́ pe *stylistics* gbọ́dọ̀ tẹ̀lẹ́. Ìlànà àkọ́kọ́ tí wọ́n dá ni fifun ní orúkọ tí yóò jẹ́ aṣeégbà fún tẹrú tọmọ nipa yíyá ọ̀rọ̀ láti orísun rẹ̀, kí a sì sọ ọ́ ní ìbámu pẹ̀lú ìhun èdè Yorùbá. Ìlànà kejì ni kí wọ́n fún un ní orúkọ Yorùbá gan-an tí yóò ṣe àfihàn ohun ti a gbà pé ìmọ̀ yìí ń ṣe àti ohun tí apá rẹ̀ ká láti ṣe.

Àbá mẹ́ta ni àwọn onímọ̀ gbé kalẹ̀. Àbá kìíní. Ní èrò àwọn onímọ̀ àkọ́kọ́, wọ́n dábàá pé kí wọ́n pè é ní *Talítîìkì*. Àwíjàre wọn ni pé kò búrú tí a bá pè é ní orúkọ yìí nítorí ìṣẹ̀dá ọ̀rọ̀ onípánda náà ni orúkọ ti wọ́n ń pe ní èdè Gẹ̀ẹ́sì tí wọ́n ṣẹ̀dá láti ara style + linguistics tí ó wá di *'stylistics'* lẹ́yìn tí ìsúnkì tí wáyé.

Àwíjàre mìíràn tí a tún ní ni pé *'stylistics'* tí wọ́n ń pè yìí kì í kúkú ṣe ojúlówó ọ̀rọ̀ gẹ̀ẹ́sì, ó jẹ́ àfetíyá láti *stylistique* tí ó jẹ́ èdè Faranse tí kò sì sí òfin tí ó ní a kò lè yá ọ̀rọ̀ láti inú èdè míràn wọnú èdè Yorùbá nípa yíyá ọ̀rọ̀. Ìró rẹ̀ kàn jọra pẹ̀lú tí Gẹ̀ẹ́sì ní. Fún ìdí èyí, tí a bá yá a wọnú èdè Yorùbá tí a pè é ní Talitíìkì kò burú rárá, nítorí yóò fara pẹ́ bí àwọn elédè míràn lágbàyéé ṣe ń pè é ni. Àti pé, ó fẹ́rẹ̀ máa sí èdè tàbí àṣà tí kì í yá ọ̀rọ̀ tàbí ìmọ̀ tó bá jẹ kárí ayé bẹ́ẹ̀ lò. Bí èyí bá rí bẹ́ ẹ̀, kí ló dé tí a kò lè ṣe é fún irú ìmọ̀ yìí kí ó lè ní àwòmọ́ káríayé

Àléébù kìíní tí àbá yìí ní ni pé, irú ìsínjẹ orúkọ báyìí kò fi taratara buyì kún èdè Yorùbá nítorí ṣe ni yóò dàbí ẹni pé èdè Yorùbá sì wà ní ìgbèkùn èdè míràn ni, àti pé ó lè fi èdè Yorùbá hàn bí i pe kò kápa láti ṣe iṣẹ́ ìjìnlẹ̀ tó bá òdé òní mu ni láì yá ọ̀rọ̀ lò. A sì mọ̀ pé irú èrò yìí kó rí bẹ́ẹ̀ rárá nítorí ó fẹ́rẹ má si ìmọ̀ kan tí a kò le fi èdè Yorùbá kọ́ tàbí ṣàlàyé rẹ̀. A ti ní èdè ìperí lóríṣiríṣi lórí ẹ̀kọ́ Sáyẹ́ǹsì, ètò ìṣèlú àti ìṣírò lédè Yorùbá. Àléébù kejì tí a tún lè tọ́ka sí ni pé irú orúkọ bí Talítîìkì kò fi bẹẹ ní àgbékà lorí ọ̀rọ̀ kankan tí o ní ìtumọ̀ nínú èdè Yorùbá.

Àbá kejì tí àwọn onímọ̀ kan tún dá ni kí a má a pè é ní *ìmọ̀ sítâì*. Àwíjàre wọn ni pé órúkọ yìí ṣe rẹ́gí pẹ̀lú iṣẹ́ tó ń ṣe nígbà tí a ń ṣe àmúlò ìmọ̀ yìí. Orúkọ tí wọ́n dá lábàá yìí, ìyẹn *ìmọ̀ sítâì* gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ṣe ṣaájú pé ohun tí a mọ sì ìṣọwọ́-ṣe ìyẹn

*'style'* ni nǹkan ṣe púpọ̀ pẹ̀lú iṣẹ́ ọnà níbi tó ti ṣan wà gan an. Nígbà tó dé inú lítíréṣọ̀ tán, ló di ohun èlò tí a fi ń ṣe àyẹ̀wò lítíréṣò. Àwíjàre mìíràn tí wọn ní ni pé tí a bá wo èrò yìí, kìí ṣe ohun tí a lè fọwọ́ rọ́ sápákan. Ìdí ni pé bí a bá mú òǹkọ̀wé méjì tí wọ́n kọ̀wé lórí kókó ọ̀rọ̀ kan náà, fún ìdí abájọ kan náà àti láàárín àwùjọ kan náà, ìṣọwọ́lo-èdè wọn ní láti yàtọ̀ síra wọn nígbà tí a bá wo bí wọn ṣe ṣe àgbèkalẹ̀ iṣẹ́ wọn. Nítorí ìdí èyí, ìṣọwọ́lo-èdè wọn ní láti yàtọ̀ síra.

Àléèbù àbá yìí ni pé orúkọ yìí, kò ṣeku kò ṣẹyẹ ni, ó ṣe àmúlò Yorùbá díẹ̀ àti ọ̀rọ̀ àyálò náà. Àléèbù mìíràn tí a ṣàkíyèsí ni pé, orúkọ yìí kò sọ pàtó irú sítáìlì tí ìmọ̀ yí dálé lórí, gẹ́gẹ́ bí a ti sọ saájú pé oríṣiríṣi sítáìlì ló wà, bí sítáìlì ìrìn, ìwọsọ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Tí a bá fi ojú yí wò ó, a ó rí pé orúkọ yí kù díẹ̀ káàtó.

Àbá kẹ́ta. Ní ibi àpérò tí àwọn onímọ̀ èdè Lítíréṣọ̀ àti Ímọ̀ mìíràn tí ó jẹmọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá ṣe ní Òṣogbo lọ́dún 1983 ní wọ́n ti fẹnu kò lórí èdè ìperí Yorùbá fún ìmọ̀ yìí. Orúkọ tí wọ́n fẹnu kò láti máa pè é ní ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè. A ri pé orúkọ tuntun yi sún mọ ohun àti iṣẹ́ tí ìmọ̀ yí gùnlé. Gbogbo ọ̀nà afọ̀ pátápátá ní ìmọ̀ yí kó tán láìyọ́ ọ̀kankan sílẹ̀ títí tó fi kan àwọn ọnà àti àbùdá ìṣọwọ́lo-èdè àti àmúlò èdè lóríṣiríṣi, yálà èyí tí a kọ sílẹ̀ tàbí sọ lẹ́nu.

Ìṣòro kejì tí a tún kíyèsí pé ó súyọ ni fífún ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ni oríkì, ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé, bí àwọn lámèétọ́ ṣe pọ̀ tó bẹ́ẹ ni oríkì tí wọ́n fún ìmọ̀ yi ṣe pọ̀ tó. Oníkálukù kàn ń roko sọ́dọ̀ ara rẹ̀ ni, ìhà tó kọ sí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ní wọ́n wò tí wọ́n fi fún un ní oríkì. Ohun pàtàkì tí a rí fàyọ ní pé gbogbo oríkì wọ̀nyí mọ́ ìmọ̀ ìṣọwọ́lo èdè mótímọ́tí bí etí tì í mọ́ orí.

Ìṣòro kẹta tí ó kọjú ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè wá láti ọ̀dọ̀ àwọn onímọ̀ tó bí ìmọ̀ yí sí àwùjọ iṣẹ́ ọnà. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé èrò wọn kò papọ̀ lórí ohun tó yẹ kó jẹ́ àtunbọ̀tán ìmọ̀ yí láwùjọ iṣẹ́ ọnà àti ẹ̀ka ìmọ̀ tó yẹ kó fì sí, láàárín ìmọ ẹ̀dá-èdè àti ọ̀rọ̀ lámèétọ́ lórí lítíréṣọ̀. Àkíyèsí wa ni pé nígbà tí wọ́n ṣe ìdásílẹ̀ ìmọ̀ yìí, ẹnu wọn ò kò lórí bí ìmọ̀ yí yóò ṣe dàgbà. Gbogbo nǹkan wọ̀nyí ló pa kún ìṣòro tí ìmọ̀ yìí n kojú láwùjọ àwọn lámèétọ́. Pẹ̀lú gbogbo àríyànjiyàn tó wáyé yìí, kò sí ìlànà kan gbòógì tàbí òpó kan tí a là kalẹ̀ fún ìmọ̀ yìí tàbí tẹ̀lé nígbà tí a bá fẹ́ ṣe àmúlò rẹ̀ nínú àyẹ̀wò iṣẹ́ ọnà, irú èyí tó wù kó jẹ́.

Ìṣòro kẹ́rin ni èyí tó sọ pé abẹ́ ẹ̀ka-ìmọ̀ wo ló yẹ kí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè wà, ìyẹn bóyá kí ó wà ní òmìnira gẹ́gẹ́ bí ẹ́ka ẹ̀kọ́ kan ni tàbí kí ó wà lábẹ́ ẹ̀ka-ìmọ̀ mìíràn, gẹ́gẹ́ bí *Semantics* ṣe wà lábẹ́ *linguistics*.

Pẹ̀lú gbogbo àwọn ìṣòro tó súyọ yìí, a rí ìmọ̀ ìsọwọ́lo-èdè gẹ́gẹ́ bí irin iṣẹ́ kan pàtàkì nínú iṣẹ́ ọnà tí a lè gbà ṣe àlàyé, ìtúpalẹ̀, àpèjúwe, ìtọpinpin àti ìgbéléwọ̀n fún iṣẹ́ ọnà àti fún àwọn afèdèṣọnà.

## 7.0 *Ìpín kẹ́rin*: *Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè Yorùbá lóde òní*

Fún ìgbà pípẹ́ ni èdè àìyédè ti wà láàárín àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ àti onímọ̀ ẹ̀dá-èdè, ohun tó fa àríyànjìyàn yìí ni pé, àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ ní onímọ̀ ẹ̀dá-èdè kò ní ẹ̀tọ́ láti ṣe ìtúpalẹ̀ àti ìgbéléwọ̀n fún iṣẹ́ ọnà èyíkéyìí, wọ́n ní àtojúbọ̀ lásán ni, kì í ṣe ojúṣe àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè. Ṣùgbọ́n àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè kò fara mọ́ èrò yìí, wọ́n ní sáyẹ́nsì ni èdè jẹ́ àti pé èdè ni a fi ń ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọnà, nítorí náà, ó gbọ́dọ̀ máa hùwà ní ìbámu pẹ̀lú òfin tó jẹ́ òpómúléró sáyẹ́nsì fún èdè. Àríyànjìyàn yìí mú ìfàsẹ́yìn bá ìdàgbàsókè ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè díẹ̀. Ṣùgbọ́n lónìí, èdè àìyédè yìí ti ń di ohun ìgbàgbé, nítorí àṣepọ̀ tó dán mọ́rán ti wà láàárín àwọn onímọ̀ méjèèjì yìí. Ní ẹ̀ka ẹ̀kọ́ ìmọ̀ Yorùbá ní yunifásitì àti ilé ẹ̀kọ́ Ẹ́ń siì, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lítíréṣọ̀ ti ń gba ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè, bákan náà ni àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ẹ̀dá-èdè ń gba ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú lítíréṣọ̀.

Ẹ̀wẹ̀, a ti rí nínú àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ lóde òní tó gbé ìtúpalẹ̀ àti ìgbéléwọ̀n íṣẹ́ wọn lórí tíọ́rì ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè. Lára wọn ni Bámgboṣé (1968), Yáì (1971) tó fi ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè ṣe ìtúpalẹ̀ ẹsẹ ifá, Ọlábọ̀dé (1981), Owólabí (1992) Ọlátẹ́jú (1998), Òjó (2013), Fáladé (2021) abbl. Pẹ̀lú ìtẹ̀síwájú yìí, àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ àti onímọ̀ ẹ̀dá-èdè ti rí i pé kí ọ̀tún wẹ òsì, kí òsì wẹ ọ̀tún ní ọ̀rọ̀ ìbàṣepọ̀ wọn gbọ́dọ̀ jẹ́.

Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè bí a tí ṣàlàyé ṣaájú pé láti ọ̀dọ̀ àwọn aláwọ̀ funfun ló ti ṣàn wá teerete bí omi inú agbada, a ṣe àkíyèsí pé ó ṣe é ṣe kí ìmọ̀ yìí ti wà láwùjọ Yorùbá kí ètò mọ̀ọ́kọ mọ̀ọ́kà tó dé àwùjọ wa. Ṣùgbọ́n tí a kò kọ ibi ara sí. Tí a bá wò ó dáradára, a máa ń ṣe ìdájọ́ pé ẹnìkan mọ ọ̀rọ̀ sọ ju èkéjì lọ tàbí pé ẹnìkan mọ àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ ju ẹlòmíràn lọ, nígbà tí a bá ń ṣe èyí, ó yẹ kí a béèrè lọ́wọ́ ara wa, kín ni ọ̀pá ìdiwọ̀n tí a ń lò fún irú àkíyèsí yìí. Ìmọ̀ ìsọwọ́lo-èdè ni, nítorí ó jẹ mọ́ ọnà tí a gbà ń ṣe ètò èdè kí a tó gbé èrò ọkàn wa jáde fún olùgbọ́.

Ẹ̀wẹ̀, tí a bá wo àwọn ayẹyẹ tí a ń ṣe ní ilẹ̀ Yorùbá lọ́kan-ò-jọ̀kan, a ó rí pé a ń ṣe àmúlò ìmọ̀ yíi dáradára. Fún àpẹrẹ, tí a bá ń ṣe ayẹyẹ ìdána ìyàwó, àwọn obìnrin méjì ni ó ń kojú ara wọn, ọ̀kan yóò ṣojú fún ìdílé ọkọ àti èkejì fún ti ìyàwó. Irú àwọn obìnrin tí wọ́n máa ń yàn fún irú ipò yìí máa ń mọ àyínìke àti àyínìpadà èdè Yorùbá, tí wọ́n sì máa ń gbójú gbónu nínú ọ̀nà ìgbàṣafọ̀ lèdè Yorùbá. Nígbà tí wọ́n bá ń ṣiṣẹ́ yìí, ṣe ni wọ́n máa ń jẹ bí ìgbà tí a rán òfófó níṣẹ́ ni. Ọ̀díwọ̀n kan ni a lò kí a tó yan irú àwọn èèyàn yìí. Tí a bá wò ó dáradára, ìmọ̀ ìṣọwọ́lò-èdè ni a ṣàmúlò níbẹ̀. Nígbà míràn, tí a bá wo ẹnìkan, a lè sọ pé ẹnu rẹ̀ dùn púpọ̀, kì í ṣe nítorí pé ó fí iyọ tàbí oyin sẹ́nu sọ̀rọ̀ ni, ohun tí a ṣe àkíyèsí ni pé ọ̀rọ̀ kì í bá irú ẹni bẹ́ẹ̀ lábo tàbí kó wá ọ̀rọ̀ tí yóò sọ tì nígbà kankan. A tún máa ń pe ẹnìkan ní aláwàdà tàbí oníyẹ̀yẹ̀, gbogbo ìgbà tí a bá ń ṣe èyí, ìdájọ́ lórí ìlò èdè ní ọ̀nà kan tàbí òmimràn ni a ń ṣe.

Tí a ba tún wo àwọn òwe àti ìtàndòwe Yorùbá, a ó ri pé ṣe ni a ń ṣe àfàyọ gbólóhùn kan tàbí méjì láti fi tọ́ka sí odidi ìtàn tó lè gbà tó ojú ìwé méjì tàbí jù bẹ́ lọ. Tí ó bá di ibi ọ̀rọ̀ sísọ, ẹni tó bá gbójú gbónú ni a ń gbóríyìn fún, tí a sì máa gbà gẹ́gẹ́ bí ẹni tó mọ ọ̀rọ̀ sọ dáradára. Gbogbo ìgbà tí a bá ń ṣe èyí, ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ni a ń ṣàmúlò yẹn. Ìmọ̀ ìsọwọ́lo-èdè tún máa ń ràn wá lọ́wọ́ láti dá àwọn ewì alohùn ni àwùjọ Yorùbá mọ ni ẹlẹ́kajẹ̀ka. Àwọn ewì alohùn bí oríkì, ìyẹ̀rẹ̀ ifá, rárà sísun, ìjálá, ẹkún ìyàwó, àlọ́ àpamọ̀ àti àlọ́ àpagbè tító tó fí kan àwọn agbègbè kọ̀ọ̀kan ní a ṣe àkíyèsí pé ìṣọwọ́lo-èdè wọn yàtọ̀ síra gẹ́gẹ́ bí Ọlátúnjí (1982) ti mẹ́nubà á. Lọ́nà kíní, wọ́n ní ìṣọwọ́-ṣe tó jẹyọ nínú ìhun tó jẹ́ àbùdá fún iṣẹ́ ọnà. Lọ́nà kéjì, wọ́n ní ìhun tó jẹyọ tó jẹ́ àbùdá afèdèṣọnà fúnrarẹ̀. Nítorí náà, ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ewì wọ̀nyí ló ní ìṣọwọ́lo-èdè tirẹ̀ láàyè ọ̀tọ̀ nígbà tí a ba ń ṣe àyẹ̀wò wọn.

## 8.0 Ìsọnísọ́kí

Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè jẹ́ ẹ́ka ìmọ̀ tó tuntun jẹ jáde láti inú èrò àwọn onímọ̀ èdè tí o lérò pé lámèyítọ́ íṣẹ́ ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀ máa ń ṣègbè. Ìmọ̀ yi gùnlè ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àyọlò àti ìgbéléwọ̀n lórí iṣẹ́-ọnà pẹ̀lú ẹ́rì láti inú irú àyọlò bẹ́ẹ̀. Àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè àti lítíréṣọ̀ Yorùbá ṣe akitiyan láti fún ìmọ̀ yi lórúkọ tí ó ṣe ìtẹ́wọ́gbà. Ní ọdún 1983 níbi ìpàde èdè-ìpérí èdè àti litíréṣọ̀ Yorùbá ni wọ́n ti fẹnukò pèé ní ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè. Ọ̀kọ̀ọ̀kan oríkì ti wọ́n fún ìmọ̀ yi tẹ́lẹ̀ ni o ni àléébù àti àǹfàní tirẹ̀, ṣùgbọ́n oríkì ti wọ́n fún un yìí dàbí ẹni pé ó súnmọ́ iṣẹ́ tí ìmọ̀ yí ń ṣe bí o tilẹ̀ jẹ́ pé àtunyẹ̀wò lè ba oríkì yí lọ́jọ́ iwájú. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé láti ọ̀dọ̀ àwọn aláwọ̀ funfun ni ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ti bẹ̀rẹ̀, ohun

tí a ṣe àkíyèsí ni pé ìmọ̀ yìí ti wà láwùjọ Yorùbá ọjọ́ ti pẹ́. Ṣùgbọ́n tí kò sí ẹni kọ ibi ara si, nínú àwọn ayẹyẹ tí a ń ṣe lọ́kan-ò-jọ̀kan ni a ti ń ṣe àmúlò ímọ̀ yìí dáradára.

## 9.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

(1) Kín ni àléébù tí o rí tọ́ka sí nínú pípé ìmọ̀ yí ní Talítíikì?

(2) Kín ni ànfààní àti àléébù pípe ìmọ̀ yìí ní ìmọ̀ sítáì?

(3) Kín ní ìwúlò ìmọ̀ yìí lórí ìmọ̀ iṣẹ́ lámèyítọ́ lítíréṣọ̀?

(4) Ṣàlàyé ní ṣókí ibi tí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ti ń jẹyọ lóde òní láwùjọ Yorùbá

## 10.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéníyí and Ojo (ed). (2005). Yorùbá Linguistics and Language Use. Eritren: Africa World Press.

Awobuluyi, O. (ed) (1990). Yorùbá Metalanguage vol. ii, Ibadàn: Unviersity Press Ltd.

Bradford, D.H. (1997). *Stylistics*, London and New York: Routledge.

Esser, J. (1993). *English Linguistic Stylistics*. Tubingen, Miemeyer.

Falade, M. (2012). The Language Style and Pattern of Yorùbá Newspaper Review in Some Selected Radio Statiosn. M.A. Thesis, University of Ibadan.

Ọlátẹ́jú, M.A.O. (2004). Readings in advanced stylistics. (A monograph).

Ọpefẹyintimi, A. (1997). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lò-Èdè*. The Department of Linguistics and African Languages, Obafẹmi Awolowo University, Ile-Ife.

# MÓDÙ KEJÌ

# ÀWỌN ẸKÁ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ, AFỌ̀ ÀTI ÀWỌN OKÙNFÀ ÌYÀTỌ̀ INÚ AFỌ̀

## *Ìpín Kìíní: Àwọn Ẹ̀ka Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè*

### 1.0 Ìfáàrà

O ti kà ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kìíni nípa oríkì tí àwọn onímọ̀ fún ìmọ̀ yìí pẹ̀lú ìhà tí ẹnìkọ̀ọ̀kan wọ́n kọ sí. Bí o ṣe ń dàgbà, àwọn ìṣòro tí ó kojú àti bí ó ṣe ń jẹyọ ní àwùjọ Yorùbá lóde òní. O tún kà nípa àwọn ẹ̀ka tí ó ní, ìyẹn ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀ pẹ̀lú ìbáṣepọ̀ tó wà láàrín wọn. A ó ṣe àlàyé nípa afọ̀ àti àwọn nǹkan tí ó máa ń jẹ́ okùnfà ìyàtọ̀ inú afọ̀ kan sí òmíràn. Nínú kọ́ọ̀sì YOR 213 o ti kà nípa bí a ṣe lè dojú afọ̀ kọ àwọn fọ́nrán afọ̀ àti àwọn fọ́nrán tí ó le fa ìyàtọ̀ nínú afọ̀ kọ̀ọ̀kan. Bákan náà, nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, o ó tún kà nípa bí a ṣe lè rán èdè níṣẹ́ láti fi gbé ọnà jáde. Ìyẹn ní pé bí a ṣe lè lo èdè lọ́nà tí yóò fí iṣẹ́-ọnà hàn àti àwọn àbùdá ìlò èdè tí ó ń gbé ọnà jáde.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn tí ó bá ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, o ó le:

1. Dárúkọ àwọn ẹ̀ká tí ìmọ̀ yìí ní àti ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrín ìmọ̀ yíí àti ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè.
2. Fún afọ̀ ni oríkì àti ṣe ìdámọ̀ àwọn fọ́nrán tí o lè fa ìyàtọ̀ nínú afọ̀ kọ̀ọ̀kan.
3. Ṣe ìdámọ̀ ìsọ̀rí méjì tí a pín ìṣọwọ́lo-èdè sí.
4. Dá àwọn àbùdá èdè ewì àti èdè iṣẹ́-ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀ mọ̀.
5. Ṣàlàyé ìsọ̀rí ẹ̀hun olóòró àti ìṣọ̀rí oníbùú.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Ṣe àlàyé ṣókí lórí ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀.

2. Kín ni ìbàṣepọ̀ tó wà láàárín ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè, ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀.

3. Kín ni afọ̀? Dárúkọ àwọn ohun tí ó ń ṣe okùnfà ìyàtọ̀ afọ̀ kan sí ìkejì?

4. Dárúkọ ìsọ̀rí méjì tí a lè pín iṣẹ́ tí ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ń ṣe sí. Kín ni ìyàtọ̀ tó wà láàárín àwọn ìsọ̀rí méjèèjì?

5. Kín ni àtúnpín ìsọ̀rí èdè ojoojúmọ́?

6. Ṣàlàyé ni ṣókí ìsọ̀rí olóòrò àti onímbùú.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 *Àwọn Ẹ̀ka Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-Èdè*

Èdè ni a le pè ní irin iṣẹ́ fún lítíréṣọ̀, òun ni oníṣẹ́ ọ̀nà ń ṣe àmúlò láti gbé èrò rẹ̀ jáde fún aráyé. Èdè tó jíire ló ń ṣatọ́kùn fún èrò lítíréṣọ̀, ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè jẹ́ oríṣiríṣi ọ̀nà tí a gbà ń lo èdè ní ọ̀nà tí kò fi jọra. Ní ìpín tó tẹ̀lée ni a ó ti jíròrò àwọn ẹ̀ka ìṣọwọ́lo-èdè, ìyẹn ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti ìmọ lítíréṣọ̀ ní ṣíṣẹ̀-n tẹ̀lé.

#### 4.1.1 *Ìmọ̀ Ẹ̀dá èdè*

Ìmọ̀ ẹ̀dá èdè jẹ́ ẹ̀kọ́ nípa ṣíṣe ọ̀rínkinwín èdè àwùjọ ènìyàn kan tàbí èdè àwùjọ ènìyàn lápapọ̀. Abram (1981:94) túmọ̀ ìmọ̀ ẹ̀dá èdè gẹ́gẹ́ bí ẹ̀kọ́ nípa títo àwọn fọ́nrán inú èdè àti àkójọpọ̀ àwọn ìlànà híhun èdè àwùjọ. Ní ojú ìwòye Fowler (1996) Webb àti Kembo Sure (2008) wọn gbà pé ìmọ̀ ẹ̀dá èdè ní lílo ìlànà Ṣáyẹ́ǹsì láti fi kọ ẹ̀kọ́ nípa èdè àwùjọ. Ìgbàgbọ́ àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè wọ̀nyí ni pé àwọn ìlànà Sáyẹ́ǹsì ni a ń ṣàmúlò láti fí kọ́ ẹ̀kọ́ nípa èdè àwùjọ. A ṣe àkíyèsí pé àwọn ìlànà kan tí sáyẹ́ǹsì mú lọ́kùnkúndùn bí ìlànà ṣíṣe àwòfín (observation) àti ṣíṣe ìdánwò nǹkan (experiment) máa ń wáyé nínú àyẹ̀wò èdè (investigation). Nídìí èyí, a lè sọ pé ìlànà sáyẹ́ǹsì ni ìmọ̀ ẹ̀dá èdè sábà máa ń gùnlé láti ṣe àmójútó èdè. Fún àpẹẹrẹ, nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àyẹ̀wò ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ nínú èdè àti ṣíṣe àkójọpọ̀ èdè fún àyẹ̀wò (Data) fún ẹ̀rí àrígbámú kí

àbájádé irú ìwádìí bẹ́ẹ̀ lè fìdí ohun tí a sọ tẹ́lẹ̀ múlẹ̀, ìlànà sáyẹ̀ǹsì ni wọ́n máà ń ṣe àmúlò.

Ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè gbòòrò, díẹ̀ nínú àwọn ẹ̀ka rẹ̀ ni Fonọ́lọ́jì, Mófọ́lọ́jì, Síntáásì àti Sẹ̀mántíìkì. Ẹ̀kọ́ Fónọ́lọ́jì jẹmọ ètò àtí bátànì ìró nínú ìsọ. Mofólọ́jì jẹ́ ìmọ̀ nípa ẹ̀hun ọ̀rọ̀, síntáàsì jẹ ẹ̀kọ́ nípa àwọn òfin àti ìlànà tí a ń gbà hun gbólóhùn nínú èdè kọ̀ọ̀kan. Nígbà tí sẹ̀mántíìkì ní í ṣe pẹ̀lú ìtúmọ̀ inú èdè. Bí a tí sọ ṣaájú, pe èdè jẹ́ bí irin-iṣẹ́ kan ti a nílò fún lítíréṣọ̀, kí a tó sọ pé nǹkan dára, ó yẹ kí a lè sọ ìdi rẹ̀, ibi tí a ti ń sọ ìdí tó fi dára yìí, ni a ó ti máa tú èdè palẹ̀. Ọlátẹ́jú (1998:204) nigbà tó ń sọ̀rọ̀ lórí ipa tí ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè ń kó nínú ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀, ó ni ìmọ̀ nípa ẹ̀dá-èdè ṣe pàtàkì fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àti ìgbéléwọ̀n nítorí èdè ni lítíréṣọ̀ n lò. Nígbà ti ìmọ̀ ẹ̀dá èdè jẹ ṣíṣe àmójútó èdè ní ìlànà sáyẹ́ńsì, tí èdè jẹ́ irin iṣẹ́ fún lítíréṣọ̀, a ó wá rí pé ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè wúlò nínú ìtúpalẹ̀ àti fífún afọ̀káfọ̀ ni ìtumọ̀, yálà kíkọ sílẹ̀ tàbí èyí tí a sọ lẹ́nu.

**4.1.2** ***Lítíréṣọ̀***

Ohun ti a lè pè ní lítíréṣọ̀ jẹ́mọ àtinúdá, èyí jẹ́ àmì kan tí ó ya ènìyàn sọ̀tọ̀ sí gbogbo ẹ̀dá yòókù. Litíréṣọ̀ jẹ́ iṣẹ́ ọnà tí ó ṣàmúlò èdè, Wellek and Warren (1973). Ní èrò Adébáyọ̀ (2010), ó ṣàlàyé pé litíréṣọ̀ túmọ̀ sí iṣẹ́ àfojú-inú wò tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ènìyàn àti àwọn ẹ̀dá míràn, nibi tí ìlò èdè ti jẹ́ àrà ọ̀tọ̀, tí ìlò ajẹmẹ́wà jẹ́ olúborí. Èdè tó jíire ló ń ṣatọ́kùn fún èrò lítíréṣọ̀.

Hartman and Stock (1973) gbà pé àwọn àkọsílẹ̀ tí a gbà pé ó ṣe iyebíye tí a pamọ́ fún ṣíṣe ìgbéléwọ̀n ajẹmẹ́wà ni lítíréṣọ̀, nígbà ti Babalọlá (1967) júwe lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí akójọpọ̀ ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ ní èdè kan tàbí òmíràn, ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ tó jásí ewì, àròfọ̀, ìtàn, àlọ́, ìyànjú ìròyìn tàbí eré onítàn, eré akọ́nílọ̀gbọ́n lórí ìtàgé. Ògúnyẹmí (2002) ní a lè túmọ̀ lítíréṣọ̀ lápapọ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọnà tí a ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọ́pọ́ ọ̀rọ̀, yálà èyí tí a ṣe àkọsílẹ̀ tàbí èyí tí a pè jáde lẹ́nu, tó ní ìtumọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú ètò àti nínú ìsọ gẹ́gẹ́ bí oníṣẹ́ ọnà ṣe hun wọn papọ̀ bí ẹní hun ẹní. Lítíréṣọ̀ ń fi bí ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ṣe rí nípa ìwà àti ìṣe han àti bí ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ṣe ń kíyèsí irírí ẹlòmíràn láwùjọ. Orí òtítọ́ tàbí ohun tí ó ṣẹlẹ̀ lójú ayé ni a gbé lítíréṣọ̀ kà. Gẹ́gẹ́ bí í lítíréṣọ̀ àwọn ẹ̀yà mìíràn lágbàyé lítíréṣọ̀ Yorùbá pín sí ọnà mẹ́ta. Àwọn ní: ìtàn àròsọ, eré-oníṣe àti ewì.

### 4.1.3 *Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè*

Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè jẹ́ ẹ̀kọ́ nípa èdè nínú lítíréṣọ̀, gẹ́gẹ́ bí a ti ṣàlàyé ní módù kìnní, ṣẹ̀ṣẹ̀dé ni ìmọ̀ yí láwùjọ ìmọ̀ ẹ̀kọ́. Ṣùgbọ́n lónìí, ó ti ní àyè pàtàkì nínú ìtúpalẹ̀, àlàyé àti ìgbéléwọ̀n lítíréṣọ̀. Ranne (1960) ní ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ni a ń lò láti gbé èrò ọkàn ẹni jáde sí olùgbọ́, tí a tún lè pè ní ọnà tàbí ẹ̀sọ́ tí oníṣẹ́ ọnà kan fi ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ rẹ̀ tó sì ya iṣẹ́ yìí sọ̀tọ̀ gedegbe sí ti ẹlòmíràn. Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ń jẹ́ kí a mọ àrà tí oníṣẹ́ ọnà fi èdè dà nínú iṣẹ́ rẹ̀.

Frye àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ (1985) gbà pé ìmọ̀ yìí (style) ni a lè tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí àbùdá àdáni tàbí ọ̀nà tí afèdèṣọnà kan gbà ṣe àgbékalẹ̀ èrò rẹ̀ sí olùgbọ́. Ní àfikún, a lè gba ìṣọwọ́lo-èdè gẹ́gẹ́ bí abala iṣẹ́ kan nínú ìtúpalẹ̀ ìṣẹ́ ọnà tó ń yọ kòmóòkun èrò, tó tún ṣe àlàyé oríṣiríṣi ọnà tó ń jẹ jáde nínú èdè kan gẹ́gẹ́ bí àbùdá tó jẹ mọ́ ẹ̀bùn sọ̀rọ̀sọ̀rọ̀ àti bátánì síntáàsì tí a fi ṣe àgbékalẹ̀ iṣẹ́ ọnà.

### *4.2 Ìpín Kejì:* **Ìbáṣepọ̀ Tó Wà Láàárín Àwọn Ìmọ̀ Yìí.**

Inú ládugbó èdè ni lítíréṣọ̀ ti ń bùwẹ̀, búmu. Èdè ni irin iṣẹ́ tí lítíréṣọ̀ ń lò láti dánilárayá àti kọ́ni lẹ́kọ̀ọ́. Ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè jẹ ẹ̀kọ́ èdè ní ìlànà sáyẹ́ǹsì nígbà ti ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ń ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà láti yọ kòmóòkun èrò, tí ó sì tún ń ṣe àlàyé oríṣiríṣi ọnà tó wà nínú èdè kan tàbí iṣẹ́ ọnà kan. Ọlátẹ́jú (1998) nígbà tó ń sọ́rọ̀ lórí ipa ẹ̀dá-èdè nínú síṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀, ó ni ẹ̀dá-èdè pèsè ìgbésẹ̀, ètò àti àwòkọ́ṣe tí a lè ṣe àmúlò nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà èyíkéyìí. Ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè dàbí ṣọ̀tún ṣòsì tí kò ba ibìkan jẹ láàárín ìmọ̀ lítíréṣọ̀ àti ìmọ̀ ẹ̀dá èdè. Òun ni a ń lò láti ṣe ìtúpalẹ̀ fún iṣẹ́ ọnà. Kí a tó sọ pé iṣẹ kan dára ó ní láti jẹ́ pe a ti ṣe ìtúpalẹ̀ àti ìgbéléwọ̀n èdè tí oníṣẹ́ ọnà fi dáṣọ ró irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ ni.

Ní tí èrò Widddowson (1975) lórí ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín àwọn ìmọ̀ yìí, ó ṣàlàyé pé, ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ń di àlàfo tó wà láàárín lítíréṣọ̀ àti ẹ̀dá-èdè ni. Ó ṣàkíyèsí pé imọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ń jẹ kí iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ yéni dáadáa nípa ríran akẹ́kọ̀ọ́ lọ́wọ́ láti yiri iṣẹ́ ọnà kan pẹ̀lú ìrírí tó ní. Fún ìdí èyí, ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ń sípayá oríṣiríṣi àwọn èròjà èdè ti oníṣẹ́ ọnà ṣe àmúlò láti mú kí iṣẹ́ rẹ̀ rẹwà. Ẹ̀kọ́ ẹ̀dá-èdè ṣe pàtàkì ní ṣíṣe ìtúpalẹ̀ àti ìfọ̀síwẹ́wẹ́ lítíréṣọ̀, ó pèsè èròjà tàbí tíọ́rì fún síṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ ọnà èyíkéyìí.

### 4.3 *Ìpín Kẹ́ta*: *Kín ni Afọ̀*

O ti kà pé a ń lo ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè láti ṣe ìtúpalẹ̀ fọ́nrán inú afọ̀ kí àwọn àbùdá èdè tí o mú kí irú afọ̀ bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí afọ̀ mìíràn. Ohun tí a ń sọ ni pé àmúlò ìmọ̀ yìí máa ń ṣe àwárí bí a ṣe lè lo èdè ní ọ̀gángán ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí a ó fi mọ ìyàtọ̀ ìlò èdè bẹ́ẹ̀ sí òmíràn. Lákọ̀ọ́kọ́ kín ni afọ̀? Afọ̀ ni a lè ṣe àpèjúwe gẹ́gẹ́ bí ohun tí a pè jáde lẹ́nu tàbí ṣe àkọsílẹ̀ láti ìbẹ̀rẹ̀ dé òpin. Afọ̀ lè jẹ́ ìwé ìtàn, ewì tàbí eré oníṣe. Bákan náà, afọ̀ ní láti ní olùwà, ìyẹn ẹni tí ó ṣẹ̀dá irú afọ̀ bẹ́ẹ̀. Lára àwọn ohun tí ó lè ran aṣafọ̀ kan lọ́wọ́ lọ́nà tí afọ̀ yóò fi ni àgbọ́yé tàbí àkàyé ni ọjọ́ orí, ìmọ̀ ti o ní, ìrírí èyi to ṣàgbà ọgbọ́n àti ìmèdèélò.

### 4.4 *Ìpín Kẹ́rin*: *Àwọn Okùnfà ìyàtọ̀ inú Afọ̀*

Ẹ̀sẹ́ kan kìí dédé ṣẹ, kí àsọyé àti àgbóyé tó wà láàárín aṣafọ̀ àti òsùnsùn afọ̀ àwọn nǹkan kan ló máa ń darí aṣafọ̀ tí yóò fi gbé afọ̀ rẹ̀ kalẹ̀ lọ́nà ti èròǹgbà rẹ̀ yóò fi jọ tàbí wá sí ìmúṣẹ. Afọ̀ lè jẹ́ èyí tí a sọ lẹ́nu tàbí kọ sílẹ̀, ó yẹ kí a fikun-un pé aṣàfò tó ni ìmèdèélò kò ṣe àkọ́sorí nǹkan wọ̀nyí, ṣùgbọ́n bárakú ni ó jẹ́ fún un. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ṣe ṣáájú pé ti ẹni méjì bá ṣe ìròyìn ohun kan tàbí àpèjúwe ìṣẹ̀lẹ̀ kan náà, ìyàtọ̀ ní láti wà nínú àpèjúwe wọn. A ó mẹ́nu ba awọn ohun tí ó lè ṣe okùnfà yìí ní ìpín yìí. Àwọn ohun tí ó lè ṣe okùnfà inú afọ̀ nìwọ̀nyí:

1. Àdúgbò tàbí, ọ̀gangan-ìṣẹ̀lẹ̀
2. Orí-ọ̀rọ̀ àpèjúwe
3. Ìmọ̀sílára aṣàpèjúwe
4. Iṣẹ́ tí àpèjúwe ṣe.

#### 4.4.1 Ọ̀gangan-ìṣẹ̀lẹ̀

Àdúgbò tàbí ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ jẹ́ pàtàkì lára okùnfà ìyàtọ̀ inú afọ̀ èyíkéyìí. Fọ́nrán yi ni ó ń ṣe okùnfà ìyàtọ̀ bí ẹnìkan ṣe lè ṣe àpèjúwe ohun kan tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ kan náà ní ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Fún àpẹẹrẹ, bí ẹnìkan ṣe lè ṣe àpèjúwe ìṣẹ̀lẹ̀ kan láàrín ojúgbà rẹ̀ àti níwájú ọ̀gá rẹ̀ tàbí ní àgọ́ ọlọ́pàá. A ó rí pé ìgbóyà yóò wà ní ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ àkọ́kọ́ ju ti èkejì lọ. Àṣàyàn ọ̀rọ̀ tàbí gbólóhùn tí yóò lò láàárín àwọn ojúgbà rẹ̀ gbọ́dọ̀ yàtọ̀ sí èyí tí yó lò ni àgọ́ ọlọ́pàá nítorí tòfintòfn ni ààtò àpèjúwe rẹ̀ ní láti jẹ́. Bákan náà, ṣíṣe afọ̀ ìbínú sí àgbàlágbà gbọ́dọ̀ yàtọ̀ sí èyí tí a ṣe fún ojúgbà ẹni. Ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ni ó

fi ẹnìkan hàn bí ẹni tí ó mọ ọ̀rọ̀ sọ tàbí mọ àgbékalẹ̀ afọ̀. Gẹ́gẹ́ bí òwe Yorùbá kan tí ó sọ pé, aṣọ ìgbà là á dá fún ìgbà. Nítorí náà, ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ ní o máa ṣe atọ́kùn ìlò èdè nínú àgbékalẹ̀ afọ̀.

### 4.4.2 Orí-ọ̀rọ̀ Àpèjúwe

Fọ́nrán tí ó ṣe pàtàkì ni orí-ọ̀rọ̀ àpèjúwe jẹ́ nínú afọ̀, ìdi ni pé òun ni ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ yóò máa yí po àti pé oun kò yí padà. Nígbà míràn, tí aṣàfọ̀ bá ní òye kíkún nípa orí-ọ̀rọ̀, èyí lè mú àyípadà bá orí-ọ̀rọ̀. Fún àpẹẹrẹ, nigbà tí ẹnìkan tí ó ní òye tàbí ìmọ̀ nípa ayò títa bá ń ṣe àlàyé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí eré tí ó mú àròjinlẹ̀, ìfaradà àti sùúrù lọ́wọ́, ẹni tí kò ni ìmọ̀ nípa rẹ̀ lè ka sí eré àwọn olóràayè tàbí ìfi àkókò ṣòfò àti eré àwọn aláìníṣẹ́.

### 4.4.3 Ìmọ̀sílára Aṣàpèjúwe

Èyí ni ìhà tí aṣàfọ̀ kọ sí orí-ọ̀rọ̀ tí ó ń sọ̀rọ̀ lé lórí. Ó ṣe é ṣe kí ó ní ìfẹ́ sí orí ọ̀rọ̀ náà tàbí kí ó ma ní ìfẹ́ sí i. Nígbà míràn ó lè fi aáyan àti ìkáànú hàn, ọ̀dájú àti àìbìkítà hàn, ìhà tí ó kọ sí afọ̀ yí ni yóò fi àwọn ọ̀rọ̀ àti ìpèdè rẹ̀ hàn. Bí àpẹẹrẹ, tí ọmọ ẹgbẹ́ òṣèlú kan ba fẹ́ ròyìn èsì ìdìbò láàárín ẹgbẹ́ tí ó nífẹ sí àti ẹgbẹ́ míràn a ó ṣe àkíyèsí pé kò ni ṣe àìṣègbè fún ẹgbẹ́ tí ó ní ìfẹ́ sí. Bí ẹgbẹ́ tí ó ní ìfẹ́ sí bá borí, ìròyìn tí yóò sọ ní pé àwọn èèyàn gba ti ẹgbẹ́ náà ju ti èkéjì lọ. Tí ó ba wa jẹ́ pé wọ́n borí ẹgbẹ́ tirẹ̀ ni, yóò tún rí nǹkan sọ láti gbè sẹ́yìn ẹgbẹ́ tó ní ìfẹ́ sí. Ọmọ ẹgbẹ́ kọ̀ọ̀kan kò lè ṣàì ṣègbè fún ẹgbẹ́ rẹ̀ nítorí ìmọ̀sílára tí ó ní. Wo àwọn àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí tí ó ń sọ nípa ẹnìkan tí kò wá síbi iṣẹ́:

a. Ó pa iṣẹ́ jẹ

b. Ó gbàyè láti ṣe ìtọ́jú ara ẹ̀

d. Ko ni nǹkan ṣe

e. Ó ṣe àìlera

ẹ. Dákú dájí ló ń ṣe

A lè ṣe àkíyèsí pé a lè lo èyíkéyìí nínú àwọn ìsọ òkè yìí láti fi ìmọ̀sílára hàn nípa ohun tí ó ṣẹlẹ̀. Orí-ọ̀rọ̀ náà kò yàtọ̀, orí ọ̀rọ̀ ni pé ẹni tí a ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ kò wa sí ibi iṣẹ́. Nínú ìsọ yìí, (a) kò fi ìmọ̀sílára ìfẹ́ hàn, (b) fi ìfẹ́ àti ìkáànú hàn, (d) fi ìmọ̀sílára

ìkóríra hàn, (e) fi ìkáànú, ìfẹ́ àti bíbìkítà hàn, síbẹ̀ ó ń tọka pé ẹni tí a ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ kò sí níbi iṣẹ́, nígbà tí (ẹ) fi hàn pé ìkórira, àìláàánú àti ọ̀dájú ni ẹni tí ó ń sọ̀rọ̀ nípa ẹni tí kò wá síbi iṣẹ́ yi. Ìlò èdè inú afọ̀ máa ń fi ìmọ̀sílára aṣàfọ̀ hàn, yàtọ̀ sí orí-ọ̀rọ̀ tàbí òsùnsùn afọ̀, nínú ìsọ kan.

### 4.4.4 Iṣẹ́ Afọ̀

Gẹ́gé bí a ti ṣe àlàyé ṣaájú, tí aṣàfọ̀ bá ń ṣe afọ̀ ni ọ̀gangan-ìṣẹ̀lẹ̀ kan, tí orí-ọ̀rọ̀ si wà tí o ń ṣe afọ̀ lé, tí a sì rí ìmọ̀sílára rẹ̀, ó ní láti ní iṣẹ́ kan pàtó ti ó fẹ́ fi afọ̀ jẹ́ ní. Ẹni tí ó bá ni làákàyè kì í sábà ṣe nǹkan kan láì nídìí. Ìdí yí ni a lè pè ní iṣẹ́ tí aṣàfọ̀ rán afọ̀ rẹ̀. Nígbà míran, afọ̀ lè jẹ́ iṣẹ́ tí a ran tàbí kí ó má jẹ́ ẹ. Èyí dúró lórí àkíyèsí àwọn okùnfà ìyàtọ̀ inú afọ̀ tí a mẹ́nubà ṣaájú. Bí àpẹẹrẹ, Yorùbá ní *'pẹ̀lẹ́'* ni akọ àti abo. Nínú ilé tí ìyàwó jẹ́ méjì, tí ọ̀kan bá kí ìkejì pẹ̀lẹ́ tí wọn sì rẹ́rin ín sí ara wọn, ó ní láti jẹ́ pé ni ọ̀gangan ìṣlẹ̀lẹ̀ yẹn, àjọṣepọ̀ tí ó gún wà láàárín wọn ni. Tí kì í bá ṣe ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀ tàbí kí àwọn méjèèjì jẹ́ ọlọ́rọ̀ ara, ìjà àti èdè àìyedè ni yóò dà. Ní àsìkò tí afọ̀ bá mu ohun tí a ń fẹ jáde, ó jẹ́ iṣẹ́ tí a ran-an. Tí afọ̀ bá mú pọ́n-ọ́n-na lọ́wọ́, tí òsùnsùn afọ̀ kò si mọ ohun tí ó yẹ láti ṣe, ìyẹn ni pé afọ̀ kùnà iṣẹ́ tí a rán an nìyẹn àyàfi tí aṣàfọ̀ bá mọ̀ọ́mọ̀ ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ láti mú pọ́n-na wáyé ni kí o lè lóye ohun tí a ń sọ dáadáa. Wo àwọn ìwé ìléwọ̀ ìsàlẹ̀ yìí:

1. **Ìwé Ìléwọ́ A**

Orúkọ: ________________________________________

Ipò: __________________________________________

Ọjọ́ ìbí: ______________________________________

Ìlú, Ìjọba Ìbílẹ̀: ________________________________

Àdúgbò: ______________________________________

Ìwé-ẹ̀rí: ______________________________________

2. **Ìwé Ìléwọ́ B**

Orúkọ: ________________________________________

Àdúgbò: ________________________________________

Ẹ̀yà/Èdè: ________________________________________

Àwọ̀ ojú: ________________________________________

Onídúró: ________________________________________

Ìwọ yóò ṣe àkíyèsí pe ìwé ìléwọ kọ̀ọ̀kan ni iṣẹ́ tí ó ń jẹ́ àti ibi tí a ti le rí ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn. Tí o bá wòó dáadá, o ó rí pé ìyàtọ̀ wà láàrín wọn. Ọ̀kan ń tẹnumọ́ *'Ìwé-ẹ̀rí'* nígbà tí èkéjì tẹnu mọ onídùúró, àwọn ìwé ìléwọ́ méjèèjì n fẹ kí ẹni tí ó bá fọwọ́ si júwe ara rẹ̀ ni. O ó ṣe àkíyèsí pé ìwé ìléwọ́ **A** jẹ́ ti onígbọ̀wọ́ ẹnìkan tí o ń wa iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ si ni ìwé ìléwọ́ B níláti jẹ́ ti ẹni tí o fẹ́ gba ìwé ìrínnà lọ sí ilẹ̀ òkèèrè.

Ẹ̀wẹ̀, láti fi bi ìyàtọ̀ ṣe máa ń wáyé nínú afọ̀ hàn, jẹ́ ki a gbà pé wọn ni kí a ṣe àpèjúwe ẹni méjì, tí ẹnìkan nínú wọn jẹ ààyò tàbí ọ̀rẹ́ ẹni, tí ẹnìkéjì kì í ṣe olùkù tàbí ọ̀rẹ́ ẹni ṣùgbọ́n tí ìrísí wọn jọra. Ó yẹ kí o fojú inú wò ó pé ṣíṣe àpèjúwe wọn ni láti yàtọ̀ díẹ̀ síra.

***Àpèjúwe***

| | Ìrísí gan-an | | Ọ̀rẹ́ tàbí ààyò ẹni | | Ẹnìkan ṣa |
|---|---|---|---|---|---|
| 1. | Etí fífẹ̀ | 1 | Etí rẹ̀ fẹ̀ níwọ̀n | 1 | Etí rẹ fẹ̀ bí etí ehoro |
| 2. | Ó kọ ilà | 2 | O fá àbàjà | 2 | Ilà ojú rẹ ri bí ẹni tí o bá ẹkùn jà |
| 3. | Ẹnu fífẹ̀ | 3 | Ẹnu rẹ̀ fẹ̀ níwọ̀n | 3 | Ẹnu rẹ̀ fẹ́rẹ̀ẹ́ yá dé ìpàkọ́. |

O ó ri pé àpèjúwe ìrísí ẹni tí a n júwe gan an ni òpó àkọ́kọ́ jẹ yọ ni òpó kejì àti ẹ̀kẹ́ta. Àpèjúwe òpó kejì fi ìfẹ́ tí a ní sí ẹni tí a n júwe hàn nígbà tí òpó kẹ́ta fi ìkóríra hàn. Ìyàtọ̀ tí ó wà nínú ìṣọwọ́ ṣàpèjúwe yìí ni o fi ìmọ̀sílára ẹni tí o ń ṣe àpèjúwe náà hàn nípa bi aṣàfọ̀ ṣe lo èdè.

Bákan náà, bi a ṣe n lo ọ̀rọ̀-arọ́pò-orúkọ nínú èdè àti àṣà Yorùbá n fi ohun tí a ni lẹ́mìí hàn. Bí àpẹẹrẹ, ó jẹ́ àṣà Yorùbá kí ìyàwó máa lo ẹ/ẹ̀yin/yín fún ọkọ rẹ̀, ṣùgbọ́n ṣá, tí àwọn méjèèjì ba ti ń lo o/ìwọ fún ara wọn, ó lè jẹ́ àṣà ìgbàlódé ti wọ́n yan lààyò láti fi ìbàṣepọ̀ ọ̀rẹ́ sí ọ̀rẹ́ hàn. Ṣùgbọ́n níbi ti ọkọ ti n lo ẹ/ẹ̀yin/yin fún ìyàwó, a o rí pé ibi ńlá ni ọkọ yẹn tí yan ìyàwó tàbí ẹni tí o ju ọkùnrin yẹn lọ lo fẹ. Tàbí ti ọmọdé ba ń lo o/ìwọ fún àgbàlágbà tí o jù ú lọ, a ó ṣe àkíyèsí pé alárìfíín tàbí oníbàjẹ́ ni irú ọmọ bẹ́ẹ̀. Ohun tí ó jẹ́ kí a rí ìyàtọ̀ nínú ìlò èdè wọ̀nyí ni àwọn fọ́nrán okùnfà mẹ́rin tí a ti ṣàlàyé lókè yìí ìyẹn ọ̀gangan-ìṣẹ̀lẹ̀, orí-ọ̀rọ̀, ìmọ̀sílára àti iṣẹ́ afọ̀.

### 4.4.5 Ìsọníṣókí

Lára àwọn ẹ̀ka ìmọ̀ yìí ni ìmọ̀-ẹ̀dá èdè àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀. Ọ̀rínkiniwín èdè àwùjọ ènìyan kan tàbí lápapọ̀ ni ó jẹ ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè lógún nígbà ti ìmọ̀ lítíréṣọ̀ fí ọgbọ́n atinudá ẹnìkọ̀ọ̀kan hàn. Ṣọ̀tún ṣòsì tí ò ba ìbìkan jẹ́ ni ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè jẹ́ pẹ̀lú àwọn ẹ̀ká rẹ̀ méjèèjì yìí. Ó ń dí àlàfo tí ó wà láàárín wọn. Àwọn fọ́nrán mẹ́rin ni ó lè ṣe okùnfà ìyàtọ̀ nínú afọ̀. Àwọn ni ọ̀gangan-ìṣẹ̀lẹ̀ èyí ni o ni fí aṣàfọ̀ hàn bí ẹni tí òyé ye tí ó si mọ bí a ṣe n gbe afọ̀ kalẹ̀ ti yóò wà ni ìbámu pẹ̀lú irúfẹ́-afọ̀ ti o ń ṣe. Ìgbékalẹ̀ ẹni ti o n sàfọ̀ lórí ọ̀rọ̀ kan ṣe pàtàkì nítorí èyí ni yóò jẹ́ ki a mọ bóyá ìmọ̀ aṣàfọ̀ kún tàbí kò kún lórí orí ọ̀rọ̀ afọ̀ kan. Ìhà ti aṣàfọ̀ ba kọ si afọ̀ òsùnsùn afọ̀ tó ń ṣe ni yóò fi ìmọ̀sílára rẹ̀ hàn. Aṣàfọ̀ ni láti ni iṣẹ́ tí o fẹ́ kí afọ̀ jẹ́ ni ìgbàkúgbà tó ba ń ṣàfọ̀. Èròngbà rẹ̀ yìí ni iṣẹ́ afọ̀.

## 5.0 *Ìpín Karùn-ún*: *RÍRÁN ÈDÈ NÍṢẸ́*

**5.1** A lè pín iṣẹ́ tí èdè ń ṣe sí oríṣiríṣi ọ̀nà. Ní àkọ́kọ́, ó lè ṣe ìtúpalẹ̀ àti ìdámọ̀ àwọn àbùdá àdání èdè ojoojúmọ́. Lọ́nà kéjì, ó tún lè ṣe ìtúpalẹ̀ àti ìdámọ̀ àwọn àbùdá àdání fún èdè ewì. Èyí rí bẹ ẹ nítorí a lè lò èdè ni oríṣiríṣi ọnà. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé tí a ṣe ni ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá, èdè lè ṣe ju iṣẹ́ kan lọ nínú afọ̀, síbẹ̀, iṣẹ́ kan ni láti lóòrìn ju ọ̀kan lọ. Èyí tí o lóòrìn jù dúró lórí fọ́nrán tí èdè dojú kọ nínú àwọn fọ́nrán afọ̀ ṣíṣe. Bákan náà, ìyàtọ̀ ní láti wà nínú bí a ṣe ń lo èdè lábẹ́ àwọn ìsọ̀rí méjèèjì tí a mẹ́nubà lókè yìí, ìyẹn èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì.

### 5.1.1 Èdè Ojoojúmọ́

Irúfẹ́ ìpèdè yìí ni a ń lò fún ìbánisọ̀rọ̀ láwùjọ, ìtakùnrọsọ láàárín ọkọ àti aya, láàárín ọ̀rẹ́ sì ọ̀rẹ̀ tàbí ẹ̀gbọ́n sí àbúrò, ọ̀gá sí ọmọ-ìkọ́ṣẹ́, abbl. Irú afọ̀ báyìi ní ètò, ìlànà, ìjánu àti òfin tí ó de ọ̀nà ìgbàṣafọ̀, o kò lè ṣàdédé jálu ọ̀rọ̀ láì tẹ̀lé òfin gírámà èdè tí wọ́n là kalẹ̀, ìjánu àti òfin ni láti wà tí yóò de ìgbékalẹ̀ wọn. Àti pé o jẹ́ onígbẹ̀fẹ́, ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé a kì í ṣe àkọsílẹ̀ tàbí ronú ohun tí a fẹ́ sọ kí a tó hun wọ́n pọ̀. Ohun tí ó jẹ́ àfojúsùn ìpèdè ojoojójúmọ́ ni ìgbọ́ra-ẹni-yé làarin olùsọ àti olùgbọ́.

### 5.1.2 Èdè Ewì (Èdè Iṣẹ́ Ọnà Aláwomọ́ Lítíréṣọ̀)

Gẹ́gẹ́ bí o ti kà nínú YOR 213, nígbà tí a bá dojú èdè kọ àwọn fọ́nrán afọ̀ ṣíṣe mẹ́fẹ̀ẹ̀fà, a ń rán èdè nísẹ́ kan nìyẹn irú iṣẹ́ tí a rán èdè ni yóò sọ àbájáde rẹ̀. Tí a bá fi èdè ṣe ìbáwí, iṣẹ́ tí a fẹ ki ó ṣe ní àtúnṣe. Ẹ̀wẹ̀, tí a bá fi èdè gbé ọnà jáde, a ń fẹ́ kí èdè ṣe iṣẹ́-ọnà ni. Nígbà tí a ba ń ṣe èyí, iṣẹ́-ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀ yóò jáde. Àrògún àti ẹwà èdè tí a lò níbí ló fa ìyàtọ̀ èdè afọ̀ ojoojúmọ́ àti èdè iṣẹ́ ọnà aláwòmọ̀ lítíréṣọ̀ tí a mọ̀ sí èdè ewì. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, irú àwọn ìhun èdè afọ̀ máa ni àwọn ìhun kan tí a lè fi dá wọn mọ̀ yàtọ̀. Bí àpẹẹrẹ; àlọ́ àpamọ̀ ní bátànì ìhun tí a lè fi mọ̀-ọ́n yàtọ̀, bẹ́ẹ̀ ni ẹsẹ Ifá ní bátànì ìhun tirẹ̀, àrọ̀ jíjá náà ni bátànì tirẹ̀, ẹkún ìyàwó náà ní bátànì tirẹ̀ abbl. Èdè ewì jẹ́ aláìgbagbẹ̀fẹ́, ó má a ń rú òfin gírámà èdè ojoojúmọ́.

Kí àlàyé ohun tí a ń sọ lè yé ọ dáadáa, wo àpẹẹrẹ méjì ìsàlẹ̀ yí tí ó jẹ́ pé orí ọ̀rọ̀ kan náà ní wọ́n ń sọ ṣùgbọ́n tí ó jẹ́ pé bí a ṣe hun èdè ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn sọ ọ̀kan di èdè afọ̀ ojoojúmọ́ tí èkejì sì jẹ́ èdè iṣẹ́ aláwomọ́ lítíréṣọ̀ (èdè ewì).

> Tí a bá bọ eégún àti òòṣà, tí orí ẹni bá fọ ire.
> Tí a kọ̀, tí a kò tún dá ẹbọ fún àlùpàyídà, ó ṣeéṣe kí ire bọ́ lọ́wọ́ ẹni
> Bí ó ṣe ṣẹ̀lẹ̀ sí Ọlásùnbọ̀ tí o jẹ ọmọ bíbí inú Dàmọ́lá
> Nígbà tí wọ́n sọ fún un pé ọwọ́ rẹ̀ kò ní tẹ ire
> Wọ́n ni kí ó lọ bọ eégún ilé àti
> Kí o tún bọ òrìṣà ọjà.
> Wọ́n tún ni kí o lọ rú ẹbọ àlùpàyídà tí ó jẹ́ àwo òde.

Wé àpẹẹrẹ (ii):

> B’á a béégún, b’òòṣà, b’orí ẹni fọ’re
> B’á ò bá dábọ àlùpàyídà, ire a máa bọ́ lọ́wọ́ ẹni.
> Dá F’Ọlásúnmbọ̀, ọmọ Dàmọ́lá
> Tí wọ́n l’ọ́wọ́ rẹ̀ ò níi tó’re

Wọ́n ní ó b'eégún ilé
Wọ́n ní ó b'òòṣà ọjà
Wọ́n ni k'ó dábọ àlùpàyídà awo òde.

O ó ṣe àkíyèsí pé àwọn àpẹẹrẹ méjèèjì yàtọ̀ sí ara wọn nítorí ìhun èdè inú wọn. Àpẹẹrẹ (i) jẹ́ èdè ṣákálá nígbà tí àpẹẹrẹ (ii) jẹ́ èdè ọlọ́nà. Nítorí ìdí èyí a lè sọ pé àpẹẹrẹ (i) gba gbẹ̀fẹ̀ nígbà tí (ii) kò gba gbẹ̀fẹ̀. Ìtúmọ̀ èyí ni pé, èdè ewì kò gba gbẹ̀fẹ̀, ó gbọ́dọ̀ ní ọnà nínú. Nínú àpẹẹrẹ (ii), o ó ṣe àkíyèsí àwítúnwí alákùdé ní ìlà 5 sí 7 nínú:

Wọ́n ni ó -----
Wọ́n ni ó -----
Wọ́n ni ó -----

Bákan náà ni pọ́n-ná tí ó jẹ jáde nínú b'eégún àti b'òòṣà. Mímọ̀-ọ́m mọ̀ lo àwọn ọnà èdè báyìí ni ó jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ ìyàtọ̀ tó wà láàárín èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì. Ìṣewẹ́kú ni o jẹ́ pàtàkì nínú ọnà gbígbé jáde nínú èdè ewì. Ìyẹn ni pé tí a bá yan wúnrẹ̀n ọ̀rọ̀ kan ṣaájú, wúnrẹ̀ tí yóò ṣe wẹ̀kú pẹ̀lú rẹ ni a tún yàn láti gbé ìhun jáde. Bí a ṣe ń yàn àti bí a ṣe ń hun wúnrẹ̀n pọ̀ yìí ni a pín sí ìsọ̀rí olóòró àti oníbùú. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé méjì ni a pín ìsọ̀rí yíí sí, àwọn méjèèjì wọnú ara wọn ni bí eégún ṣe wọnú ẹran tí wọ́n sì jọ ń ṣíṣẹ́ pọ̀ láti gbé ẹwà jáde nínú ìhun gbólóhùn.

### 5.1.3 Ìsọ̀rí Olóòrò àti Oníbùú

Tí a bá sọ̀rọ̀ nípa ìsọ̀rí olóòrò àti oníbùú láti ṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọnà, ohun tí a ni lọ́kàn ni yíyan ọ̀rọ̀ tó tọ̀ àti tó yẹ nínú ọ̀pọ̀ yanturu irú rẹ̀ míràn tí ó lè wà nípò kan náà tàbí ti a lè fi rọ́pò èyí tí a yàn. Ní pàtàkì, ohun tí a ń sọ ní pé, a gbọ́dọ̀ ṣe àṣàyàn ọ̀rọ̀ tí yóò gbé irúfẹ́ afọ̀ tàbí àká-ọ̀rọ̀ tí èdè kan ni tí ó jẹ́ pé àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ jọ wà ní ọ̀wọ́ gírámà kan náà. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé, àwọn ọ̀rọ̀ kan wà tí o lè dára ní yíyàn ju òmimràn lọ bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé inú ọ̀wọ̀ kan náà ni wọ́n wà. Bí àpẹẹrẹ:

(iii) Ìrẹ l'o ní kí ẹ máa bá mi rẹ́
Ẹtù l'ó ní kí ẹ máa fire tù mí
Erèé ní ẹ f'owó ire rè mi.

Ó o ri pé akéwì ṣe àmúlò àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ àti ọ̀rọ̀ ìṣe tó ba ara wọn mu nínú àyọlò òkè yìí. Ó lo ọ̀rọ̀ ìṣe 'rẹ̀' láti àrà ọ̀rọ̀ orúkọ *irẹ̀* láti ṣàpèjúwe ìhà ti ó fẹ́ kí àwọn èèyàn kọ sí ohun, bákan náà, 'tù' láti ara ọ̀rọ̀ orúkọ *Ẹtù* àti ọ̀rọ iṣẹ́ *'rè'* láti àrà *erèé*.

Ohun tí á ń sọ ni pé, akéwì fọkàn sí wúnrẹ̀n ọ̀rọ̀ tó ti yàn ṣaájú kí ó tó yan èyí tí yóò tẹ̀le láti gbé ẹwà èdè jáde.

Lábẹ́ ìsọ̀rí oníbùú ni a ti máa ń hun àwọn wúnrẹ̀n ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tí a yàn lábẹ́ ìsọ̀rí olóòró pọ̀ di odidi gbólóhùn. Fún àlàyé, tí o ba wo àpẹẹrẹ (iii) tí a lò lókè yìí, akéwì lo àjùmọ̀rìn/ìbádọ́gba ọ̀rọ̀ nípa lílo, 'rẹ̀' láti ara 'irẹ̀', 'tú' láti ara 'ẹtù' àti 'rè' láti ara 'erèé' yàtọ̀ sí ìbámu ìró wọ̀nyí, o yẹ́ kí o tún ṣe àkíyèsí ìfọ̀rọ̀dárà nínú ìṣẹ̀dá àwọn ọ̀rọ̀ iṣẹ̀ láti ara ọ̀rọ̀ orúkọ nínú àyọlò yìí. Ohun tí a ń sọ ní pé, bí ìlà ewì tí ń tẹ̀lé ara wọn yìí, ìbátan wà láàárín ìlà kọ̀ọ̀kan sí èkejì, ìtúmọ̀ ti ìlà kọ̀ọ̀kan bá ní ni yóò bẹ̀rẹ̀ ìlà kejì. Àwọn onímọ̀ sọ pé tí a bá yọ ọ̀rọ̀ kan tàbí ìlà kan kúrò nínú ìlà ewì nínú ètò olóòrò. Irú ewì bẹ́ẹ̀ lè ma ní ìtumọ̀ mọ́ nítorí ọ̀rọ̀ tí a yọ kúrò yíí yóò mú kí ìtumọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ ìsàlẹ̀ yìí:

Obìnrin tó torí ọlà
Fi nǹkan sójú ara rẹ̀
Hún ùn!
Òdodo ọ̀rọ̀
Ilé ìbímọ lojú ara
Kìí ṣe ilé fàyàwọ́
Hún ùn! Òdodo ọ̀rọ̀

O ó ṣe àkíyèsí pé ìlà kárùn-ún ní ó ń túmọ̀ ojú ara tí ó wà ní ìlà kejì, èyí túmọ̀ sí pé a ò lè yọ fọ́nrán tàbí ìlà kan kúrò nínú ìlà ewì kí ó tún ní ìtumọ̀. Lọ́rọ̀ kàn, àṣepọ̀ wà láàárín ìlà kíiní sí ìlà kéje nínú ewì òkè yìí.

## 6.0 Ìsọníṣókí

Oríṣi méjì ni èdè pín sí, àwọn ni ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ojoojúmọ́ tí a mọ̀ sí èdè ojoojúmọ́ (EO) àti ìṣọwọ́lo-èdè iṣẹ́-ọnà aláwomọ́ lítíréṣọ̀ tí a mọ̀ sí èdè ewì (EE). Èdè Ojoojúmọ́ jẹ́ onígbẹ̀fẹ̀, ọnà ni ó jẹ́ lájorí fún èdè ewì nítorí ìdí èyí, kò gba gbẹ̀fẹ̀. Ìṣewẹ̀kú tí o wáyé nínú èdè ewì ní ó fa ìpínsísọ̀rí méjì, ìyẹn ìsọ̀rí olóòró àti ìsọ̀rí oníbùú tí a ti ń yan wúnrẹ̀ ọ̀rọ̀ tó bá bá àyè kan mu ní àsìkò kan àti ni Ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ kan tí a sì hun irú àwọn wúnrẹ̀n ọ̀rọ̀ tí a bá yàn ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé pọ̀ ní ìsọ̀rí oníbùú nínú ìhun gbólóhùn lọ́nà tí yóò fi gbé ẹwà èdè jáde.

## 7.0 Iṣẹ́ Síṣe

1. Ṣàlàyé ṣókí lórí ibi ti ìmọ̀ ìṣọwọ́lo-èdè ti ń jẹyọ lóde òní láwùjọ Yorùbá.

2. Kín ni ìmọ̀ ẹ̀dá èdè àti ìmọ̀ lítíréṣọ̀? Ní ṣókí, ṣàlàyé ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti lítíréṣọ̀?

3. Ṣàlàyé ni ṣókí àwọn ohun tí ó lè ṣe okùnfà ìyàtọ̀ afọ̀ kan sí èkejì

4. (a) Ṣàlàyé ìsọ̀rí méjì tí a lè pín èdè sí.

   (b) Kín ni ìyàtọ̀ tó wà láàárín àwọn ìsọ̀rí méjèèjì?

   (d) Kín ni àbùdá èdè ewì.

6. Kín ni ìsọ̀rí olóòró àti onírbùú?

## 8.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéníyí and Ojo (ed). (2005). Yorùbá Linguistics and Language Use. Eritren: Africa World Press.

Akporobaro, F.B. (2004). *African Oral Literature*. Lagos: Princeton Publishing.

Bamgbose, A. (2005). Yorùbá Metalanguage. Vol. 1, Ibadan: University Press Ltd.

Bamisilẹ, O. (1989). Ìwúlò Lìngúísíìkì fún àtúpalẹ̀ ewì Yorùbá. Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria. Special edition.

Bradford, D.H. (1997). *Stylistics*, London and New York: Routledge.

Enkvist, N.E. (1972). 'On the place of Style in Linguistic theories' in *Literary Style*: A Symposium Ed. Saymour Chatman, London, Oxford University Press Ltd.

Finch, G. (2000). *Lingustic Terms and Concepts*. Macmillian Ltd.

Ọlátẹ́jú, M.O.A. (1998). A Syntatic Approach to literary discourse analysis: the Yorùbá example. Ph.D Thesis, University of Ibadan.

Ogunyẹmi, R. (1998). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lo-èdè*. Lekoba Publishers, Ondo.

Ọpefẹyintimi, A. (1997). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́lo-Èdè*. The Department of Linguistics and African Languages, Obafẹmi Awolowo University, Ile-Ife.

# MÓDÙ KẸ́TA

## DÍẸ̀ LÁRA TÍỌ́RÌ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ ÀTI ÀWỌN ÀBÙDÁ ÌMỌ̀ ÌṢỌWỌ́LO-ÈDÈ

***Ìpín Kìíní: Àyẹ̀wò Tíọ́rì Èdè Ojoojúmọ́***

### 1.0 Ìfáàrà

Ní ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó kọjá, o ti kà pé ohun tí ó mú kí èdè iṣẹ́-ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀ (èdè ewì) yàtọ̀ sí èdè ojoojúmọ́ ni pé gbígbé ẹwà jáde ni ó jẹ iṣẹ́-ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀ lógún. Nítorí náà, akitiyan láti gbé ẹwà jáde máa mú kí iṣẹ́-ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀ tàpá sí òfin èdè ojoojúmọ́ nígbà míràn, pàápàá èdè ewì tí ó jẹ́ ọ̀kan nínú iṣẹ́-ọnà aláwomọ̀ lítíréṣọ̀. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó jíròrò tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì bí àwọn onímọ̀ ti mẹ́nu bà á. Ní ìparí a o ṣe àyẹ̀wò díẹ̀ lára àwọn àbùdá ọnà ìṣọwọ́lo-èdè bí àwítúnwí, ìbádọ́gba gbólóhùn, àfiwé, ìsohundènìyàn, àsọrégèé, àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ àti ìfọ̀rọ̀dárà.

### 2.0 Èròǹgbà

Lẹ́yìn tí o bá ka ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tán, o ó lè ṣe àlàyé:

1. Èrò àwọn onímọ̀ kan lórí tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì.
2. Ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàrín èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì.
3. Oríṣiríṣi ọ̀nà tí èdè ewì fi lè yapa sí èdè ojoojúmọ́.
4. Àwọn àbùdá ọnà ìṣọwọ́lo-èdè

### 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

(1) Ní ṣókí, ṣàlayé:

   a. Tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ .

   b. Tíọ́rì èdè ewì.

(2) Kín ni ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì?

(3) Ṣàlàyé ọnà mẹ́rin tí èdè ewì fi lè yàpà sí èdè ojoojúmọ́.

(4) Ṣàlàyé ni ṣókí oríṣi; àwítúnwí, márùn-ún pẹ̀lú àpẹẹrẹ

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

Tíọ́rì tó rọ̀ mọ́ ìmọ̀ yìí pọ̀, gẹ́gẹ́ bí oríkì rẹ̀ ṣe pọ̀ tó náà ni tíọ́rì rẹ̀ ṣe pọ̀ tó. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí tíọ́rì èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì ni a ó gbé yẹ̀wò.

## 4.1 Èdè Ojoojúmọ́

Àwọn onímọ̀ kan gbà pé ìyàtọ̀ wà láàárín èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì, pàápàá bí èdè ewì ṣe ní òmìnira láti gbé ìhun tí ó mú ọnà jáde, èyí tí ó sábà máa ń yapa sí èdè ojoojúmọ́. Lára àwọn tó ṣe agbátẹrù tíọ́rì yí ni Haveranek (1964) Mukarovsky (1970).

1. Nínú akitiyan rẹ̀ láti ṣàlàyé ìbáṣepọ̀ tó wà láàárín èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì, Mukarovsky (1970), ní àwọn ti ń lo èdè ojoojúmọ́ ń fẹ kí èrò wọn kọjá sí ọ̀dọ̀ olùgbọ́ láìsí àṣìwí àti àṣìgbọ́ níbẹ̀ ni. Ó ní èdè ojoojúmọ́ ni a fi ń ṣàfọ̀ ni ilé ìwé, ilé iṣẹ́ ìjọba, ọjà, ilé ìjọ́sìn abbl. Ọ̀jọ̀gbọ́n yìí gbà pé gbogbo ènìyàn tó ba fi orí sọlẹ̀ sí àwùjọ kan ni àǹfààní tí ó gbòòrò láti ṣe àmúlò èdè ojoojúmọ́. Ó ní nínú àwùjọ yìí kan náà, a ṣe àkíyèsí àwọn ẹ̀dá kan gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ni ìmọ̀ nípa èdè dé àyè kan ju àwọn ẹ̀dá tó kù lọ. Ó ní àwọn wọ̀nyí ní àwọn oníṣẹ́ ọnà tí a rí lọ́kan-ó-jọ̀kan láàárín àwùjọ. Ó tẹ̀síwájú pé, èdè tí àwọn oníṣẹ́ ọnà yìí ń lò àti ọ̀nà tí wọ́n gbà ń lò ó gbé pẹ̀ẹ́lí ju èdè ojoojúmọ́ lọ.

2. Ó ni èdè ojoojúmọ́ jẹ́ ohun tó ti mọ́ wa lára, bárakú ni fún tawo tọ̀gbẹ̀rì. A ò nílò láti kọrí sí oko ìtumọ̀ kí èdè tó ye wa. Nítorí náà, a máa ń ṣe àgbékalẹ̀ èdè ojoojúmọ́ ní ìbámu pẹ̀lú kókó ọ̀rọ̀ tí a ní lọ́kàn tàbí tí a fẹ́ sọ gan an.

3. Nítorí náà, èdè tí a ṣètò láìsí ìrònú kan tó jinlẹ̀ ni èdè ojoojúmọ́ jẹ́. Èdè Yorùbá gẹ́gẹ́ bí àwọn èdè mîìràn lágbàyéé ni ìhun:

| OR | OI | AB |
|---|---|---|
| Adé | kọ́ | ilé |

4. Mukarovsky (1970) tẹ̀síwájú pé, èdè kọ̀ọ̀kan ló ní òfin tí ó de gírámà rẹ̀, ó ní nínú èdè ojoojúmọ́, kò rọrùn láti rú òfin gírámà èdè bẹ́ẹ̀, ẹnikẹ́ni tí ó bá rú àwọn òfin gírámà èdè yìí yóò dàbí kògbédè ní.

## 5.0 Ìpín kejì: Tíọ́rì Èdè Ewì

### 5.1 Èdè Ewì

Àwọn onímọ̀ kan gbà pé èdè ewì wà láàyé ọ̀tọ̀ ni àti pé ó yàtọ̀ pátá sí èdè ojoojúmọ́. Nígbà tí àwọn kan fi àáké kọ́rí pé kò sí ohun tó ń jẹ èdè ewì. Àwọn onímọ̀ tó gba ọrọ yí bí ìgbá ọtí ni Mukarovsky (1970) àti Fowler (1971).

1. Nínú akitiyan Mukarovsky (1970) ó pín èdè sí ọ̀nà méjì, ó pé ọ̀kan ni èdè ewì àti èkéjì ni èdè ojoojúmọ́. ó gbà pé àwọn tó ń lo èdè ojoojúmọ́ ń fẹ kí èrò wọn kọjá sí ọ̀dọ̀ olùgbọ́ láìsí àṣìwí tàbí àṣìgbọ́ níbẹ̀ rárá. Ó ni ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ fún èdè ewì nítorí pé èdè ewì máa ń ya bátànì èdè tirẹ̀ lọ́tọ̀ débi pé a lè sọ pẹ̀lú ìgbóyà pé ṣe ló mọ̀ọ́mọ̀ rú òfin gírámà èdè ojoojúmọ́ ni.

2. Lójú Fowler (1971) nígbà tó ṣe àgbéyẹ̀wò èrò yìí, ó ní ohun tí òun ṣe àkíyèsí ni pé èdè àmúlò wà lóríṣiríṣi ọ̀nà. Ọ̀nà tí ewì bá gbà ṣe àmúlò èdè, èdè àmúlò tirẹ̀ nìyẹn dípò kí a sọ pé èdè ewì ń yapa sí èdè ojoojúmọ́.

3. Mukarovsky (1970) tẹ̀síwájú pé, a ò le è fi gbogbo ara sọ pé èdè ewì kò ní ìbátan kankan pẹ̀lú èdè ojoojúmọ́. Ó ní èdè ojoojúmọ́ jẹ́ ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún èdè ewì ó ni, èdè ewì díjú, ó le koko, ẹwà èdè ni ó jẹ ẹ́ lógún. Àkíyèsí tiwa ni pé bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èdè ewì ń yapa sí èdè ojoojúmọ́ síbẹ̀, inú àká èdè ojoojúmọ́ ni èdè ewì ti ń ṣọlá.

## 6.0 Ìpín Kẹ́ta

### 6.1 Ìyàtọ̀ láàárín èdè ewì àti èdè ojoojúmọ́

A ṣe àkíyèsí pé èdè ojoojúmọ́ wà ní ìbámu pẹ̀lú òfin gírámà èdè bí òfin fonọ́lọ́jì, mofọ́lọjì, ṣẹ̀mántìíkì àti síntáasì ṣùgbọ́n tí èyí kò rí bẹ́ẹ̀ fún èdè ewì. Èdè ewì máa ń mọ̀ọ́mọ̀ rú àwọn òfin gírámà èdè nítorí òmìnira tí ewì ní, àgbọ́yé àti àsọyé ni ó jẹ èdè ojoojúmọ́ lógún nígbà tí ó jẹ́ ète ajẹmẹ́wà ni ó jẹ èdè ewì lógún.

Ẹ̀wẹ̀, àwọn gbólóhùn kan tí a wò bi aláìnítumọ̀, tàbí kòbójúmu nínú èdè ojoojúmọ́ lè jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà nínú èdè ewì. Gẹ́gẹ́ bí Mukarovsky (1970) tí sọ, èdè ewì ń gbé èdè yọ kọjá àlà láti tì í síwájú. Nítorí náà, ìgbéyọsíwájú ni iṣẹ́ èdè ewì. Ó ní bí èdè ojoojúmọ́ ṣe dúró lójú kan tó, ni àǹfààní láti dàárú náà ṣe pọ̀ tó. Ìdí ni pé èyí ni yóò mú

kí èdè ewì jẹ jáde, ó ní èdè ojoojúmọ́ jẹ́ ohun tó ti mọ́ wa lára, tí kò yani lẹ́nú, ṣùgbọ́n èdè ewì ń gbé èrò àti ìlò àwọn ọ̀rọ̀ kan síwájú fún àkíyèsí. Irú ojú yòówù ká fi wò ó, oríṣi ọnà ti a lè gbà lo èdè ojoojúmọ́ pọ̀ ju èdè ewì lọ, bẹ́ẹ̀ ti ọ̀rọ̀ bá kan gbogboògbò, èdè ojoojúmọ́ ni a ń ṣàmúlò. Èdè ewì jẹ èdè awo nígbà tí èdè ojoojúmọ́ wà fún ì̀lò tawo tọ̀gbẹ̀rì. Inú ládugbó èdè ojoojúmọ́ ni èdè ewì tí ń bùwẹ bùmu.

Ẹ̀wẹ̀, ọnà ìṣọwọ́lo-èdè kìí sábà pọ̀ nínú èdè ojoojúmọ́ kí ó má bà á pagidínà ìtúmọ̀ tàbí ìgbọ́ra-ẹni yé, ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ fún èdè ewì. Ọnà-èdè pọ̀ nínú èdè ewì nítorí adùn àti ẹwà èdè ni ó jẹ ẹ́ lógún.

Gẹ́gẹ́ bí èrò Ọ̀jọ̀gbọ́n Mukarovsky (1970) yìí, ìyapa ni ó ya èdè ojoojúmọ́ sọ́tọ̀ sí èdè ewì. Mukarousky (1970) wa tọ́ka sí oríṣi ọnà mẹ́rin ti èdè ewì fi ń yapa sí èdè ojoojúmọ́. Èyí ni a ó ṣàlàyé ni ìpín kẹ́rin.

## 7.0 Ìpín kẹ́rin

## 7.1 Ìyapa èdè ojoojúmọ́ àti èdè ewì

Oríṣi ìyapa mẹ́rin ní a ṣe àkíyèsí nínú èdè ewì tó yàá sọ́tọ̀ sí èdè ojoojúmọ́. Àwọn ni: ìyapa oníròó, ìyapa ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀, ìyapa onígírámà àti ìyapa onítumọ̀.

### 7.1.1 Ìyapa Oníròó

Ohùn mẹ́ta ni èdè Yorùbá ní, ara àbùdá fáwẹ̀lì sì ni àwọn ohùn wọ̀nyí ti ń jẹyọ. Èdè ewì máa ń ṣe àmúlò ohùn wọ̀nyí lọ́nà tí yóò fi yàtọ̀ sí èdè ojoojúmọ́. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Mo *ríbà*
Mo ***ríbá*** baba tó bími lọ́mọ
Àkànmú òpó ọmọ Ọ́làtóyọ̀si

Ọ̀rọ̀ ti a kọ yàtọ̀ lókè yìí, ríbá ni, dípò ríbà, ṣùgbọ́n akéwì yí rò pé tí òun bá pè é bẹ, kò ni wà ní ìlànà ewì, èyí ló fi pè é ní ríbá. Tún wo;

(b) Ọmọ igi kan *igi kàn*
Tó ya dínà ní Sapó ilé

(d) Adìyẹ bàbá mi kan láéláé
Adìyẹ bàbá mi kan *làèlàè*
Owó ní jẹ, kì í jàgbàdo.

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ yàtọ̀ ní àpẹẹrẹ (b) àti (d) yapa sí èdè ojoojúmọ́, *igi kàn* kò ní ìtúmọ̀ kan pàtó nínú èdè Yorùbá. Ṣùgbọ́n akéwì lò ó láti bu ẹwà kún ewì. Bákan náà ni (d), irú ọ̀rọ̀ báyìí kò lè rí àyè nínú èdè ojoojúmọ́ àyàfi nínú èdè ewì ni irú àwọn ọ̀rọ̀ báyìí ti lè jẹyọ. Ní ọpọ̀ ìgbà, tí akéwì ba lo ìlànà yìí, o máa n fara jọ ifọ̀rọ̀dárà. Bí wọ́n bá wá pe méjì nínú gbólóhùn ọ̀kan yóò ní ìtumọ̀ nígbà tí èkejì yóò dàbí ìfọ̀rọ̀dárà lásán. Àpẹẹrẹ a-d fi èrò yìí múlẹ̀ bí a ti ríi lókè yìí.

### 7.1.2 Ìyapa ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀

Nínú ewì, ọ̀nà mẹ́tà ni ìyapa ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ti lè wáyé. Àkọ́kọ́ ni lílò àwọn ọ̀rọ̀ àtijọ́ ìyẹn àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ti di ìkàsìn tó jẹ́ pé bí a kò bá ṣọ́ra, wọn ò ní pẹ́ lọ sí òkun ìgbàgbé. Àwọn àgbà tó mọ̀ èdè nìkan ni ìlò wọn kù sí lọ́wọ́.

(a) Láyíwọ̀lá ọmọ olúkú-ewu
*Kọ̀nkọ̀sọ̀* búra pó ò ní kùlùbọ̀

(b) Ọ̀dún ǹ bá kú
*Ejiẹ* gbadíẹ̀ ìrànà mi lọ

(d) *Òjòjò* ń sògún
Ara ògún ò le

(e) *Ọlọ́kùnrùn* fẹsẹ̀ dàagùn nù

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ yàtọ̀ ni a-e lókè yìí, kò lè jẹyọ nínú èdè ojoojúmọ́ nítorí àwọn tí o mọ ìtúmọ̀ wọn kò pọ, wọ́n ti di ọ̀rọ̀ àtijọ́ nínú èdè ewì ni a ti lè bá wọn pàdé.

| | | |
|---|---|---|
| Kọ̀nkọ̀sọ̀ | - | Asẹ́ ti wọn fí sẹ́ èlùbọ́ |
| Ejiẹ | - | Ikú lo n jẹ bẹ́ẹ̀ |
| Òjòjò | - | àìsàn ni èyí túmọ̀ sí. |

Ọlọ́kùnrùn - Ẹni tí ó ní àìsàn lára bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó sin ń rìn kiri

Irú ìyapa báyì, nínú ẹsẹ̀ ifá ló ti wọ́pọ̀.

Ọnà kejì tí ìyapa ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ti lè wáyé ní lílo ọrọ̀ àyálò. Inú èdè yòówù tó ba kọjú si akéwì ni ó ti lè yá ọ̀rọ̀ lò. Ó lè yá a láti inú èdè òyìnbó tàbí èdè míràn.

(f) Baba ọkọ mi ti sáìn sọ̀rọ̀ rẹ
Báwùsá ti sáìn sóbì kó tó dé sókótó

Bóyìnbó ti <u>sáìn</u> si kòkó kó tó fò lókè
Bàbá ọkọ mi ti <u>sáìn</u> sọ́rọ̀ mi

(g) Eégún títì afàwọ̀lọ̀lọ̀

Ò-pa *dìónà* pa *kọ̀ǹdọ̀*.

Ò-dámọ-lẹ́sẹ̀ figi pààrọ̀

Ìyapa ni àwọn ọ̀rọ̀ tí a fàlà sí nídì ní f àti g yìí jẹ́, nítorí akéwì ṣe àmúlò ọ̀rọ̀ àyálò *'sáìn', dìónà* àti *kọ̀ǹdọ́* láti inú èdè Òyìnbó. Ọ̀nà kẹ́ta tí ìyapa ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀ ti lè wáyé ni nípa lílo ẹ̀ka èdè. Àkíyèsí tí a rí lórí èyí ni pé, àdúgbò tí akéwì dàgbà sí máa nípa púpọ̀ lórí yíya irú èdè bẹ́ẹ̀.

(gb) Ojú ẹkùn iná
Ẹ̀yìn ẹkùn oòrùn
<u>Lèsí máa kojú ẹkùn</u> láìsanwó

Láti inú èdè ìjẹ̀bú ni akéwì ti yá ọ̀rọ̀ tí a fàlà sì nídi yìí. Bákan náà àwọn ọ̀rọ̀ tó jẹ́ pé agbègbè kan ni wọ́n jẹ mọ́, yálà nípa ìlò tàbí ìtumọ̀ wọn, tí akéwì bá lò ó nínú ewì ìyapa ló jẹ. Bí apẹẹrẹ:

Edè (ẹ̀gúnsí) àwọn èkìtì ló ń pe bẹ́ẹ̀
Àtùpóró (ìjòkó) àwọn àkókó ló ń pé báyìí.

### 7.1.3 Ìyapa Gírámà

Irú ìyapa yìí máa ń jẹyọ lóríṣiríṣi ọ̀nà nínú ewì, ó lè jẹ àfikun tàbí àyọkúrò ẹyọ ọ̀rọ tí a lè pè ní aṣekókó gbólóhùn tàbí wúnrẹ̀n gírámà-onítumọ̀-àdámọ̀. Irú wúnrẹ̀n bẹ́ẹ̀ lè máa ni iṣẹ́ kan pàtàkì tó ń kó nínú ẹsẹ ewì, nígbà mìrán, ó lè ran ìgbésẹ̀ ewì lọ́wọ́. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Inú ọgbà koóko

Ẹ̀yìn ọgbà koóko

***Àti***

(b) Ọdẹ Aperin <u>wọ́n</u> ṣaájú
Ọdẹ ìjàyè <u>wọ́n</u> ń rọ bọ lẹ́yìn
Nítorí Àkàndé <u>náà</u> ni

Ní àpẹẹrẹ (a) o ó ṣe àkíyèsí pé kò sí ọ̀rọ̀-ìṣe ní ìlà ewì méjèèjì. Nínú ewì ní àwọn gbólóhùn báyìí ti lè jẹyọ. Nínú èdè ojoojúmọ́, bí yóò ṣe jẹyọ nì yìí:

Inú ọgbà ní kóríko
Ẹ̀yin ọgbà ní kóríko

Bákan náà ni àpẹẹrẹ (b) àwọn ọ̀rọ̀ ti a fàlà sí nídì yìí jẹ́ ìyapa nípa àfikún. Ìlò irú àwọn ọ̀rọ̀ arọ́pò orúkọ tó ń tọ́ka sí ọ̀pọ̀ ni ipò olùwà yìí kò lè ri àyè nínú èdè ojoojúmọ́.

(d) Gbogbo orí àfín ewú
Abúké ló rẹrù òòṣà má sọ̀

Ti gbólóhùn yi ba máa wáyé nínú èdè ojoojúmọ́, ó ní láti ni ọ̀rọ̀ ìṣe nínú .

Gbogbo orín àfín jẹ́ ewú
Abúké ló rẹrù òòṣà má sọ̀

Ọ̀nà mìíràn ti ìyapa fi le wáyé ni yíyí ipò àwọn ọ̀rọ̀ po lọ́nà tí kò lè wáyé ní èdè ojoojúmọ́. Fún àpẹẹrẹ:

(e) Ọgbọ́ ṣeré ṣeré wọn ò légbò
Kékeré ìròrẹ́ wọn ò lágbà

Nínú ìlà kejì àpẹẹrẹ òkè yìí, akéwì kò tẹ̀lé ìhun àpolà orúkọ bí ó ṣe yẹ kí ó wà ni èdè ojoojúmọ́. Ohun tí a ń retí ni: ọ̀rọ̀-orúkọ+ọ̀rọ̀ ẹ̀yán. Kí ó rí báyìí:

Irorẹ́ kékeré ò lágbà

Akéwì máa ń ṣe àmúlò àwọn ìyapa yìí láti le mú ki ewì dùn mọ̀ràìn mọrain létí.

### 7.1.4 Ìyapa Onítumọ̀

Ọ̀nà méjì ni a lè lò láti fi ṣàlàyé irú ìyapa tí ewì máa ń ní lábẹ́ ìsọ̀rí yìí, lákọ̀kọ́ọ́, ewì lè ṣe ìtúpalẹ̀ gbólóhùn ojoojúmọ́ tí yóò sí ṣe àtúntò fún irú gbólóhùn bẹ́ẹ̀ kó lè wá ní ìbámu pẹ̀lú èdè ewì. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Ọmọ ojú oró
Náà kúkú ni bàba mi
Tí ò jomí ọbà ò lèsun

(b) Àróúnkẹ́ awo wọn lóde Ẹ̀gbá

Aróunkẹ̀ awo òde ìjèṣà...

Ní ìlà kìíní ewì (a) lókè yìí, àwọn ọ̀rọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀tá tó tẹ̀lé ara wọn yìí jẹ́ ọ̀rọ̀ orúkọ, nínú èdè ojoojúmọ́, àwọn onímọ̀ ẹ̀dá-èdè yóò ni kò tọ́nà nítorí kò bá òfin gírámà mu. Ní ìlà kéjì, ẹ̀yan aṣàfihàn ti ó máa ń jẹyọ lẹ́yìn ọ̀rọ̀ orúkọ ni akéwì gbé wá sí ìbẹ̀rẹ̀, nígbà tí ìlà kẹ́ta jẹ́ awẹ́ gbólóhùn aṣàpèjúwe. Tí o bá wo ìhun gbólóhùn yìí, o ò ṣe àkíyèsí pé odidi gbólóhùn kan ni akéwì gé sí mẹ́ta tí ó wa ṣe àtúntò fún fọ́nrán kọ̀ọ̀kan. Olórí awẹ́ gbólóhùn kan àti gbólóhùn àfarahẹ méjì ni. Tí ó bá jẹ́ nínú èdè ojoojúmọ́, bí yòó ṣe rí nìyìí:

Ọmọ ojú oró ni baba mi.
Ọmọ ojú oró tí o jómi ọbà ó lèsun náà kúkú ni bàbáà mi.

Bákan náà, ní àpẹrẹ (b), o ó ṣàkíyèsí pé kò sí ọ̀rọ̀-ìṣe ní ìlà kìíní àti kéjì. Nínú èdè ojoojúmọ́ a lè fi ọ́rọ́-ìṣe ‘jẹ’ sí ibi tó yẹ nínú àyọlọ̀ yìí, bí yóò ṣe rí nìyìí

Àróúnkẹ́ jẹ́ awo wọn lóde Ẹ̀gbá

Aróunkẹ̀ jẹ́ awo òde ìjèṣà...

Tí akéwì bá lò ó báyìí, kò ni bu ẹwà kún èdè ewì àti pé gbólóhùn náà ti gùn jù fún ewì. Ìdí nìyí tí akéwì fi ṣe àtuntò fún un.

Lọ́nà kéjì, tí ìyapa tún ti lè wáyé ni lílo ọ̀rọ̀ kan lọ́nà tí yóò fi jẹ pọn-na ní àyè tó wà. Inú ìfọ̀rọ̀dárà ni èyí tí wọpọ̀ jù. Bí àpẹẹrẹ.

(c) Èṣù ni ta ló rú
Ta ni ò rú
Wọ́n ni ìṣekúṣe ló rú
Ayé ò rú
------------
Èṣù bá ni kí wọ́n fọwọ́ síjà
Gbogbo ayé ní
Ìṣekúṣe dáyé o

Nínú ẹsẹ̀ ifá tó wà lókè yìí, àwọn ọ̀rọ̀ tí a fàlà sí nídìí, ìyẹn *‘rú’* àti *dáyé* ni ju ìtumọ̀ kan lọ. Àwọn ìtumọ̀ ti *‘rú’* le ni nìwọ̀nyí:

ru - rú ẹbọ

- rú jáde bí ìgbà ti igi ti wọ́n ti gé bá tún yọ ewé tuntun jáde.

- rú nǹkan pọ̀

– kí nǹkan rúwé (bí igi)

Bákan náà dáyé lè ni àwọn ìtumọ̀ yìí:

Dáyé - dé ayé (kí nǹkan dé láti ibìkan)

- dá ayé mọ́lẹ̀ nínú ìjàkadì

- dá ayé tàbí kí ó ṣẹ̀dá ayé.

Àwọn akéwì máa ń lo irú àwọn ọ̀rọ̀ yìí láti bu ẹwà kún èdè ewì. Pẹ̀lú àwọn àkíyèsí wọ̀nyí, a lè sọ pé lóòọ́tọ́ ni èdè ewì yapa sí èdè ojoojúmọ́. Ṣùgbọ́n nínú àká èdè kan náà ní àwọn méjèèjì ti ń ṣọlá. Nínú èdè ojoojúmọ́ ni èdè ewì ti ń ṣe àmúlò, òun ni ó jẹ òpó fún un. Gbogbo ohun tí o lè jẹ́ àwòrán ewì ti onísẹ́ ọnà lè yà, orí èdè ojoojúmọ́ ló gbé e lé. Àṣepọ̀ tó lágbára ní ó wà láàárín èdè ewì àti èdè ojoojúmọ́, èdè ojoojúmọ́ ni èdè ewì ń lò bí o tilẹ̀ jẹ́ pé ó máa ń ṣe àtúnṣe àti àtúntò àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀, awẹ̀ gbólóhùn àti gbólóhùn lóríṣiríṣi.

Ó rọrùn fún èdè ewì láti ṣe àgbékalẹ̀ gírámà tirẹ̀ láàyè ọ̀tọ̀ kí ó lè ya àwòrán tí o fẹ fi èdè ṣe fún olùgbọ́.

## 8.0 Ìpín karùn ún

### 8.1 Àwọn ọnà ìṣọwọ́lo-èdè

Àwọn èròjà ìṣọwọ́lo-èdè ni a lè pè ni ọnà-èdè tàbí ọnà-ìṣọwọ́lo-èdè tí onísẹ́ ọnà tele jọ lọ́kan-ò-jọ̀kan láti fi gbé iṣẹ́ ọnà sí ayé. Ipa tí àwọn àbùdá wọ̀nyí ń kó nínú ìhun iṣẹ́ ọnà kò kéré. A lè pe wọn ni èròjà tó gbé iṣẹ́ ọnà dúró gẹ́gẹ́ bí odidi. Oríṣiríṣi ni àwọn àbùdá wọ̀nyí, bẹ́ẹ̀ ni kò rọrùn láti bá gbogbo wọn pàdé nínú iṣẹ́ kan. A ó wo àwọn àbùdá wọ̀nyí lọ́kan-ò-jọ̀kan.

### 8.2.1 Àwítúnwí

Àwítúnwí jẹ́ ọnà èdè pàtàki ti àwọn oníṣẹ́ ọnà ń ṣe àmúlò nínú iṣẹ́ wọn, ó fẹ̀rẹ̀ ma si ẹ̀yà lítíréṣọ̀ tí kì í lò ó, ìbá à jẹ́ eré oníṣe, ìtàn àròsọ tàbí ewì. Ọ̀nà tí wọ́n gba lò ó lè yàtọ̀ díẹ̀díẹ̀ síra wọn. Àwítúnwí ni kí oníṣẹ́ ọnà ṣe ìtẹnumọ́ tàbí àtúnsọ ohun tí ó ti sọ tẹ́lẹ̀ lóríṣiríṣi ọ̀nà fún àkíyèsí àwọn olùgbọ́. Lára àwọn onímọ̀ Yorùbá tí ó ti ṣiṣẹ́ lórí àwítúnwí ni Awobuluyi, Bamgboṣe àti Ọlátúnjí. Ẹ̀rò Bamgboṣe àti Ọlatunji bára mu lórí oríṣi àwítúnwí ti o wà, wọn pín sí ọ̀nà méjì, ìyẹn, àwítúnwí oníhùn gbólóhùn àti àwítúnwí ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀. Wọ́n tún ṣe ìpínsísọ̀rí fún àwítúnwí oníhun gbólóhùn sí ọ̀nà méjì àwọn ni: (i) Odidi gbólóhùn àti (ii) àpólà gbólóhùn. Awobuluyi pín àwítúnwí sí oríṣi ọ̀nà márùn-ún. Àwọn ní:

(a) Àwítúnwí ìró-èdè

(b) Àwítúnwí ẹyọ-ọ̀rọ̀

(d) Àwítúnwí kókó-ọ̀rọ̀

(e) Àwítúnwí ìtúmọ̀

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a o ṣe àlàyé oríṣi àwítúnwí méje. Àwọn ní:

(i) Àwítúnwí ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀

(ii) Àwítúnwí awẹ́ gbólóhùn

(iii) Àwítúnwí odidi gbólóhùn

(iv) Àwítúnwí ìró

(v) Àwítúnwí ìtúmọ̀

(vi) Àwítúnwí elétò gbólóhùn

(vii) Àwítúnwí kókó ọ̀rọ̀

1. ***Àwítúnwí Ẹlẹ́yọ Ọ̀rọ̀***

Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé kí oníṣẹ́ ọnà ṣe àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ kan ju ìgbà kan lọ nínú afọ̀. Àpẹẹrẹ:

(a) Bẹ́rú bá sá lóko olówó
Bọ́wọ́ bá tún ẹrú mú
Àtoko ìròkò doko ìrókòto
Àtoko ẹrú dóko ẹrú lẹrú ń lọ

Nínú àpẹẹrẹ òkè yìí, ẹyọ ọ̀rọ̀ tí a ṣe àwítúnwí ni ẹrú tí a fa ìlà sí nídìí. Ìgbà mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ la ṣe àwítúnwí rẹ̀. Nígbà míràn, àwítúnwí ẹyọ ọ̀rọ̀ lè má jẹyọ nínú ìsọ kan. Ọ̀rọ̀ tí a ṣe àwítúnwí rẹ̀ lè jẹyọ ni gbólóhùn méjì tí o tẹ̀lé ara wọn tàbí ti o jìnà sí ara wọn. Ṣùgbọ́n tí wọ́n jọ wà nínú afọ̀ kan náà.

(b) *Olè* ní ń mẹsẹ̀ *olè*
Ń tọ̀ lórí àpáta

Nínú àpẹẹrẹ (b), olè ni a ṣe àwítúnwí fún ní ìlà kìíní. Ìgbà méjì ni àwítúnwí yìí wáyé.

2. ***Àwítúnwí Awẹ́ Gbólóhùn***

Èyí ni kí oníṣẹ́ ọnà ṣe àwítúnwí awẹ́ gbólóhùn àkudé gbólóhùn, àpólà orúkọ tàbí àpólà-ìṣe. Bí àpẹẹrẹ:

*Ó dé'le* apẹja, Arigidi fún lẹ́ja
*Ó dé'le* àgbẹ̀, ó gb'a'ṣu, ó gbá'ta
*Ó dé'le* ará oko, ó gbẹtu, ó gbepo
*Ó dé'le* anílélókó, ó gba ohun gbogbo tán

O ó ri àwítúnwí awẹ́ gbólóhùn tí a kọ lárà ọ̀tọ̀ nínú ìlà mẹ́rin-in àpẹẹrẹ òkè yìí, nígbà míràn, awẹ̀ gbólóhùn tí a ṣe àwítúnwí rẹ̀ lè wà ní ìbẹ̀rẹ̀, àárín tàbí ni ọwọ́ ìparí gbólóhùn.

3. ***Àwítúnwí Odidi Gbólóhùn***

Ìtumọ̀ èyí ni ki oníṣẹ́ ọnà ṣe àwítúnwí gbogbo wúnrẹ́n ọ̀rọ̀ tó wà nínú ìhun gbólóhùn. Ó lè jẹ́ méjì tàbí kí ó jù bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Ọjọ́ Adárúdúrùdu mbọ̀ wá'lẹ̀ yí
Mo máṣọ t'ó mú bora

Mo maṣọ t'ó mú bora
Ọjọ́ Adárúdurùdu ḿbọ̀ wá'lẹ̀ yí
Mo maṣọ t'ó mú bora
Adárúdurùdu w'ẹ̀wù ẹ̀ha

O ó ṣe àkíyèsí nínú àpẹẹrẹ òkè yìí pé akéwì ṣe àwítúnwí ìlà kìíní ní ìlà kẹ́rin, bákan náà ó ṣe àwítúnwí *Mo maṣọ t'ó mú bọra* lẹ́ẹ̀mẹ́tẹ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ṣíṣe àwítúnwí odidi gbólóhùn lè jẹ ẹ̀ẹ̀mejì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, iye ìgbà tí a ṣe àwítúnwí dúró lórí iṣẹ́ ti a bá fẹ́ ran èdè ni àsìkò kan. Àpẹẹrẹ yí wọ́pọ̀ nínú ẹsẹ̀ ifá àti ọfọ̀ Yorùbá.

**4. *Àwítúnwí ìró***

Irú àwítúnwí yìí máa ń jọ ìfọ̀rọ̀dárà. Nínú èrò Awobuluyi, ó ni ìró ni a máa ń ṣe àwítúnwí rẹ̀ ní ọ̀pọ̀ ìgbà nínú èdè ewì Yorùbá tí a máa ń ṣiwọ́ọ́ pè ní ẹyọ-ọ̀rọ̀. Àpẹẹrẹ ni:

*Ak<u>ẹ̀</u>keè* ló ní ẹ máa <u>*ké*</u>
*Àlọ̀<u>fọ</u>hùn* ló ni ẹ máa lé <u>*fọ*</u>*hùn*
*Àgb<u>in</u>sínú* legb<u>in</u> *gb<u>in</u>*
*Àk<u>ùn</u>sínú* lẹkùn *k<u>ùn</u>*

Nínú àpẹẹrẹ yìí, àwọn ìró tí a ṣe àwítúnwí ni – *e, un, ín àti in*. Akéwì ṣe àwítúnwí ìró *e, ẹ, un, ọ* àti *in* nínú àwọn ọ̀rọ̀ tí a fàlà sí nídìí lókè yìí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé nípa ìtumọ̀, wọn ò fi gbogbo ara bára tan.

**5. *Àwítúnwí Ìtumọ̀***

Ìtumọ̀ èyí ni pé kí oníṣẹ́ ọnà gbé afọ̀ rẹ̀ kalẹ̀ lórí ìhun gbólóhùn tàbí ìlà ewì méjì tàbí mẹ́ta tí wọ́n túmọ̀ sí nǹkan kan náà láti lè fẹsẹ̀ ohun tí ó ń sọ múlẹ̀. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Rírí ń <u>sunkún àìrí bí</u>
Rírí ń <u>gbàwẹ̀ àìrí pọ̀n</u>
Ó ń <u>fọwọ́ osùn nùgiri gbígbẹ</u>
Ó rọ́mọ lẹ́yìn adìyẹ ó bú púrú sẹ́kún

Tí o bá wo àyọlò òkè yìí, o ó ṣe àkíyèsí pé èrò tó wà níbẹ̀ jẹ ọ̀kan tó ń tọ́ka sì ìdádúró ọmọ bíbí tàbí àìrọ́mọ bí. Kókó ohun tí akéwì ni lọ́kàn ló wà ní ìlà kẹrin. Àwọn ìlà kíínì si kẹ́ta jẹ àwítúnwí àkàwé ohun tó wà lọ́kàn akéwì. Ohun kan-náà ni àwọn gbólóhùn tàbí ìpèdè tí a fàlà sí lábẹ́ túmọ̀ sí, èyí tíí ṣe àírọmọbí tàbí yàgàn.

***Àwítúnwí Oníhun Gbólóhùn***

Irú àwítúnwí yìí máa ń wáyé nígbà tí oníṣẹ́ ọnà bá ń ṣe àkàwé ọ̀rọ̀ nípa ṣíṣe àtòpọ̀ èrò nínú ìhun gbólóhùn. Àbùdá yìí máa n ṣiṣẹ́ pẹ̀lú bátànì gírámà àti síntáàsì, ó wọ́pọ̀ nínú òwe àti ìgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ nínú èdè Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ:

Ẹni a ní kó fẹ́ni lójú, ata ló fi sẹ́nu
Ẹni a ní kó kíni lẹ́yìn, ẹ̀gún ló fi sọ́wọ́.
Ẹni à bá fẹ̀yìn tì ká mu dídùn ọsàn
Kíkan ló ń fún ni mu

O ó ri pé èrò kan ṣoṣo ni ìlà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tó ní bátàní ìhun kan-náà yìí ń tọka sí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìlà mẹ́ta ni òwe yìí ni. Ìwà ọ̀dàlẹ̀ àti àìní-ìgbọ́kànlé lo ń tọ́ka sí.

### 6. *Àwítúnwí Kókó Ọ̀rọ̀*

Nínú àbùdá yìí, ohun tí ó jẹ kókó ọ̀rọ̀ tàbí kókó èrò ni oníṣẹ́ ọnà ń gbé jáde nínú afọ̀ rẹ̀. Ó wọ́pọ̀ nínú ẹsẹ̀ ifá. Àwọn awo sábà máa ń ṣe àwítúnwí ìlà méjì, mẹ́ta sí mẹ́rin àkọ́kọ́ ní ìbẹ̀rẹ̀ tàbí ìparí ẹsẹ̀ ifá. Àpẹẹrẹ:

*Oníkẹ́kẹ́ ló logún*
*Alábàjá ló lọgbọ̀n*
*Adíá fún ṣ'oóróyè*
*Ọmọ aṣawo 'roko*
Tó ń sunkún àíríbí
Tí ń gbàwẹ̀ àìrípọ̀n
Wọ́n ní ó k'o kààkí mọ́lẹ̀
Ebọ ni o ṣe,
Ó gbọ rírú ẹbọ, o rú
Ó gbọ èrù àtùkèṣù
Ó tù, ó gbọ ìkárara ẹbọ ha fún un
Ijó ní jó, ayọ̀ ni yọ̀
Ó n yin awo
Àwọn awo ń yifá
*Oníkẹ́kẹ́ ló lógun*
*Alábàjá ló lọgbọ̀n*
*Adíá fún ṣ'oóróyè*
*Ọmọ aṣawo 'roko*

O ó ri pé ni ìparí ẹsẹ̀ ifá yìí, awo tún ṣe àwítúnwí ìlà mẹ́rẹ̀ẹ̀rin àkọ́kọ́ lẹ́ẹ̀kan síi.

### 8.2.1 Ìwúlò Àwítúnwí

Àwítúnwí wúlò lóríṣiríṣi ọ̀nà. Lára ìwúlò rẹ̀ ni:

(1) Ó máa n fi ohun tó jẹ́ kókó nínú afọ̀ hàn.

(2) Àwọn oníṣẹ́ ọ̀nà máa ń lò láti fi kókó èrò wọ́n hàn nínú iṣẹ́ wọn gẹ́gẹ́ bi ohun tó jẹ́ wọ́n lógún.

(3) Ó máa ń mú kí ìgbésẹ̀ ewì dánmọ́rán lọ́nà tí yóò fi bá gírámà èdè mu.

(4) Ó máa ń mu kí ìfẹ́ inú aṣàfọ̀ ó ṣẹ. Ẹ̀yí wọ́pọ̀ nínú ọfọ̀ nítorí pé ó ní iye ìgbà tí wọ́n máa ń ṣe àwítúnwí àwọn gbólóhùn kan nínú ọfọ̀.

(5) Ó tún máa ń mú kí ó rọruǹ fún olùgbọ́ láti lóye afọ̀ tí ó ń lọ lọ́wọ́ ni pàtàkì orin tàbí ìyẹ̀rẹ̀ ifá.

(6) Àwítúnwí tún dàbí ìsọ̀yè fún àwọn akéwì kí wọ́n ma bàá gbàgbé.

## 8.3 Ìbádọ́gba Gbólóhùn

Ọ̀nà èdè yìí ṣe pàtàkì pẹ̀lú ètò gbólóhùn lọ́nà tó fi jẹ́ pé oníṣẹ́ ọ̀nà yóò sín àwọn gbólóhùn tó bá ara wọ́n dọ́gba nínú ìhun kan náà. Kòṣeémánìí ni ó jẹ́ fún ewì nítorí ó máa ń jẹ́ kí ewì rọrùn láti ṣẹ̀dá, ní pàtàkì orin kíkọ. Àwọn gbólóhùn wọ̀nyí máa ń ṣe déédé pẹ̀lú ara wọn. Oníṣẹ́ ọ̀nà máa ń hun wọ́n papọ̀ bí ẹni tí ó ń hun ẹ́ní lọ́nà tí yóò fi ṣòro láti yọ ọ̀kan kúrò níbẹ̀. Àbùdá yìí máa ń fi ẹsẹ̀ ètò olóòró àti oníbùú múlẹ̀ nínú ewì. Ó máa ń mú ki ẹsẹ̀ ewì ó rọrùn láti kọ́ sórí lọ́nà ti kì í fi yá gbàgbé. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Ẹ̀yìnkùnlé lọ̀tá wà
Ilé laṣeni ń gbé

(b) Èdè ò gbóhùn ẹlẹ̀yọ̀
Bi ará ilé ò ṣe gbóhùn ará oko

O ó ṣe àkíyèsí pé àwọn gbólóhùn wọ̀nyí bá ara wọn dọ́gba nípa ìhun àti bátànì. Nínú ìbádọ́gba gbólóhùn, bí àwọn gbólóhùn yìí bá wà ní ṣíṣẹ̀-ń-tẹ̀lé, ó ṣeéṣe kí wọ́n máa túmọ̀ ara wọn tàbí ó lè jẹ́ pé ohun tí gbólóhùn àkọ́kọ́ kò sọtán tàbí sọ ní àsọyé ni èyi tó ń tẹ̀lee yóò parí. Bí àpẹẹrẹ:

(d) Apá lará, èjìká ni iyèkan.

Oríṣi ìbádọ́gba gbólóhùn mẹ́ta ni a ṣe àkíyèsí, àwọn ni; ìbádọ́gba gbólóhùn tó dẹ̀yìn kọra, ìbádọ́gba gbólóhùn tó dojú kọra àti ìbádọ́gba gbólóhùn tó wà ní ṣíṣẹ̀-ń-tẹ̀lé.

### 8.3.1 Ìbádọ́gba Gbólóhùn tó dẹ̀yìn kọ ara wọn

Àwọn gbólóhùn báyìí báramu ṣùgbọ́n wọ́n dẹ̀yìn kọ ara wọn nípa èrò nígbà tí a bá wo ìtumọ̀ àwọn kókó ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tó wà nínú gbólóhùn. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Ènìyàn *burúkú* pọ̀ bí ìgbẹ́
Ẹni *rere* wọ́n jojú lọ

(b) Ètùtù owú *ṣọ̀pọ̀*
Afárá oyin *ṣọ̀wọ́n*

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ lọ́tọ̀ lókè yìí dẹ̀yìn kọ ara wọn nígbà tí a bá wo ìtúmọ̀ wọn nínú ìhun gbólóhùn tí a ti lò wọ́n.

### 8.3.2 Ìbádọ́gba Gbólóhùn tó dojú kọ ara wọn

Àwọn gbólóhùn báyìí bá ara wọn dọ́gba, wọ́n sì kọjú sí ara wọn nípa ìtumọ̀ nígbà tí a bá wo èrò tí àwọn ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ inú gbólóhùn wọ̀nyí mú jáde. Púpọ̀ ìgbà, àwọn gbólóhùn wọ̀nyí máa ń túmọ̀ ara wọn bí àpẹrẹ.

(a) Ìṣẹ́ kìí ṣe ohun àmúṣeré
Ìyà kìí ṣe ohun àmúyangàn

(b) Apá lará
Ìgùnpá niyèkan

O ó ri pé gbólóhùn kejì ló ń ṣe kòǹkárí ìtumọ̀ gbólóhùn àkọ́kọ́.

### 8.3.3 Ìbádọ́gba Gbólóhùn Ṣíṣẹ̀-ń-tẹ̀lé

Ìhun àwọn gbólóhùn wọ̀nyí máa ń jọ ara wọn, wọ́n sì máa ń wà ní ṣíṣẹ̀-ń-tẹ̀lé nínú ètò gẹ́gẹ́ bí èrò tó wà nínú wọn bá ti pọ̀ tó. Èrò yí lè pọ̀, ṣùgbọ́n wọ́n gbọ̀dọ̀ wà nínú àká ìtumọ̀ kan náà kí wọn sì máa sọ àsọyé nípa ara wọn. Bí àpẹẹrẹ:

(a)O súré títí o ko ikú
O rìrìn gbẹ̀rẹ̀ o kàrùn
O bọ́ṣọ nílẹ̀ o jọkú lójú.

(b)Bí a á nùdí

Ikun là á mú

Bí a á lé tìróò

A yẹ pẹpẹ ẹnu

O ó ri pé àwọn èrò tó wà nínú àpẹẹrẹ òkè yí tẹ̀lé ara wọn gẹ́gẹ́ bí ìhun gbólóhùn kọ̀ọ̀kan ṣe rí. Ìsọ̀rí ọ̀rọ̀ tí akéwì lò bá ara wọn rìn, ìyẹn ni pé, ọ̀rọ̀-orúkọ bá ọ̀rọ̀-orúkọ rìn.

**Ìwúlò ìbádọ́gba gbólóhùn**

1. Ó ń ṣe okùnfà ẹwà fún gbólóhùn
2. Láì sí ìbádọ́gba gbólóhùn kò le è sí ewì. Gẹ́gẹ́ bí Hopkins ṣe sọ, ìbádọ́gba gbólóhùn ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún ewì.
3. Ó máa mú kí ẹsẹ ewì rọrùn láti kọ́ sórí
4. Ó ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àtinúdá
5. Ìbádọ́gba gbólóhùn ni orísun fún ọnà-èdè bíi àwítúnwí ìhun, àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ àti ìfohùngbohùn. Wo Ọlátúnjí (1984).

## 8.4 Ìfọ̀rọ̀dárà

Èyí ni kí onísẹ́ ọnà lo ẹyọ ọ̀rọ̀ lọ́nà tí yóò fi dàbí ẹni pé o ń fi ọ̀rọ̀ dárà lórísirísi ọ̀nà, nígbà tí a bá gbọ́ ìró irú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ nínú afọ̀ kan. Àkíyèsí fihàn pé orísirísi ìfọ̀rọ̀dárà ni a lè rí nínú ewì ní pàtàkì èdè Yorùbá. Ṣùgbọ́n orísi mẹ́ta ni a o mẹ́nubà. Àwọn ni; ìfọ̀rọ̀dárà tí ohun (Ìfohùndárà), ìfọ̀rọ̀dárà tí ìtumọ̀/oní pọ́nna àti ìfọ̀rọ̀dárà alárakò.

### 8.4.1 Ìfọ̀rọ̀dárà ti ohùn ( Ìfohùndárà)

Ìtumọ̀ èyí ni kí oníṣẹ́ ọnà fi ohùn dárà lórí sílébù ọ̀rọ̀ lọ́nà àrà tí yóò fi dàbí i pé ìtúmọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ náà yàtọ̀ nínú ìhun kan náà. Nígbà míràn, àwọn ẹyọ ọ̀rọ̀ wọ̀nyí lè máa ní ìtumọ̀ kan náà tàbí kí wọn máa ní ìtumọ̀ kan gúnmọ́ tí a lè fi inú rò nínú gbólóhùn bẹ́ẹ̀. Bí àpẹẹrẹ nínú oríkì Ọlálọmí:

(a) Ìjà kan, ìjà kàn
Tí wọ́n ń jà lọ́fà

Àpẹẹrẹ míràn:

(b) A ò gbọ́dọ̀ na babaláwo tó gbọ́fá yanranyanran
Bí a bá na babaláwo tó gbọ́fá yanranyanran
Ohun burúkú á máa já lu ohun burúkú
Ohun burùkù á máa já lu ohun bùrùkù

Oríṣiríṣi ìtumọ̀ ní oníṣẹ́ ọnà máa ń fi àbùdá yìí mú jáde níbi tí irú àwọn ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ bá ti ní ìtumọ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ṣùgbọ́n, ní ọ̀pọ̀ ìgbà, àwọn ọ̀rọ̀ tí a fi ń dárà kìí sábà ni ìtumọ̀ gan-an, bí kò ṣe ìtumọ̀ ọ̀rọ̀ tí a fi ṣe ìgbékà ìfọ̀rọ̀dárà náà. Bí o ó ti ṣe àkíyèsí nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí. Nínú èdè Yorùbá, kò sí ọ̀rọ̀ tó ń jẹ́ *kàn* tàbí *bùrùkù*, akéwì lò wọ́n láti dárà ni.

### 8.4.2 Ìfọ̀rọ̀dárà ti ìtumọ̀ tàbí Ìfọ̀rọ̀dárà onípọ́nna

Nígbàkúgbà tí oníṣẹ̀ ọnà bá lo irú ìfọ̀rọ̀dárà yìí, ó máa ń fún wa ní ìtumọ̀ tó ju ẹyọkan lọ; ìdí ni pé ìlò wọn máa ń mú pọn-na lọ́wọ́ nínú ìhun gbólóhùn. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Lọjọ́ tí àásà d’Ápòmù
Lèké dáyé

(b) Àsíá Òyìnbó dòrìṣà kékeré
T’a ń péjọ lọ̀ ọ́ bẹ́rí fún

Àwọn ọ̀rọ̀ ti a fàlà sí nídìí ní àpẹẹrẹ *a* àti *b* lókè yìí le ní ju ìtumọ̀ kan lọ ní ọ̀gangan ìṣẹ̀lẹ̀ kan. A ti ṣàlàyé èyí sẹ́yìn. Gbólóhùn yìí *Dáyé* lè túmọ̀ sí:

(1) Dé inú ayé

(2) Dá ayé mọ́lẹ̀ nínú ìjàkadì

(3) Ṣẹ̀dá ayé (ìyẹn kí wọ́n dá ayé)

Bákan náà *Bẹ́rí* lè túmọ̀ sí:

(1) Bẹ́rí (ìkíni ti ológun)

(2) Bẹ́rí (bíbẹ́ orí fún ètùtù)

### 8.4.3 Ìfọ̀rọ̀dárà alárokò

Bátànì ọ̀rọ̀ orúkọ tí a ṣẹ̀dá ni èyí sábà máa ń jẹ́mọ́. Àkíyèsí fi hàn pé kì í sí ìbáṣepọ̀ láàrín àwọn ọ̀rọ̀ orúkọ wọ̀nyí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ìṣe tí ó dàbí ẹni pé wọ́n jọ kọ́wọ́ ọ́ rìn papọ̀ nínú irú ìlà ewì bẹ́ẹ̀. Ó tún máa ń wọ́pọ̀ nínú ọfọ̀ àti àwọn àròfọ̀ mìíràn. Bí àpẹẹrẹ:

*Iré* ló ní kí ẹ máa bá mi *ré*
*Ẹtù* ló ní kí ẹ máa fi ’re *tù* mi
*Erèé* ní ẹ f’owó ‘re *rè* mi
*Ata* ló ní ẹ máa *ta* mi l’ọ́rẹ
*Amọ̀* l’ó ní ẹ wá f’owú yin *mọ̀* mí

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ yàtọ̀ yìí kò ni nǹkan ṣe pẹ̀lú ara wọn nípa ìtumọ̀, ìyẹn ni pé kò sí ìbáṣepọ̀ kan danin danin láàárín ọ̀rọ̀ orúkọ àti ọ̀rọ̀ ìṣe wọ̀nyí, wọ́n kàn ṣẹ̀dá wọn lórí àgbékà èdè ni èyí tó ní àyọrísí ìfọ̀rọ̀dárà tó ní ìtúmọ̀ ìpàrokò. (Ìfọ̀rọ̀dárà alárokò).

### 8.4.4 Ìforúkọdárà

Èyí ni kí oníṣẹ́ ọnà fi orúkọ èèyàn dárà nínú ìhun gbólóhùn. Bí àpẹẹrẹ:

(1) Ẹgbẹ̀rún <u>Sàámú</u> ò lè <u>sá</u> m’Ọ́lọ́run lọ́wọ́

(2) <u>Yẹ̀kínì</u> kan kò lè <u>yẹ̀ é</u>

(3) <u>Wíke</u> <u>wí</u> nǹkan

Àwọn orúkọ tí a fàlà si nídìí ni akéwì fi dárà

### Ìwúlò Ìfọ̀rọ̀dárà

1. Ó ń jẹ́ kí ewì dùn létí.
2. Ó ń ran àtinúdá lọ́wọ́.
3. Ó ń bu ẹwà kún ewì

## 8.5 Àfiwé

Èyí ni kí a fi nǹkan méjì wé ara wọn yálà nípa pé wọ́n jọ ara wọn, wọ́n bá ara wọn mu tàbí bá ara wọn tan. Ó jẹ ọ̀nà kan pàtàkì tí a fi lè gbé èrò afòyemọ̀ jáde kí ó lè yé àwọn ènìyàn yékéyéké. Nígbàkúgbà tí oníṣẹ́ ọnà bá lo àfiwé yìí, ó gbọdọ̀ ní nǹkan pàtàkì tó fẹ́ fàyọ gẹ́gẹ́ bí ìdí abájọ. Nígbà tí a bá fi èrò inú ẹni hàn lórí àwọn nǹkan báyìí ni a máa ń rí àfiwé. Oríṣi àfiwé méjì ni a ṣe àkíyèsí pé ó wà. Àwọn ni àfiwé tààrà àti àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́.

### 8.5.1 Àfiwé tààrà/simili

Nínú àfiwé yìí, a lè fi nǹkan méjì wé ara wọn lọ́nà tó lọ́ tààrà ti kò gba ìrònú rárá kí á tó mọ̀ pé, ṣe ni a ń fi nǹkan méjì wé ara wọn. Àwọn wúnrẹ̀n gírámà kan wà to máa ń ṣiṣẹ́ atọ́kùn fún un. Àwọn ni: bí, tó, àti jù. Wo àpẹẹrẹ wọ̀nyí:

(i) Ó dúdú *bí* kóró iṣin

(ii) Ó ń wẹ̀yìn *bí* ṣóloóò wá lálẹ́

(iii)Ó dára *bí* egbin

(iv)Ó dé akoto *bí* iná ọdẹ.

Ìtumọ̀ wọn ni pé, wọ́n rí bákan-náà. Bákan náà ni a tún ní atọ́kùn jù, irú ọ̀rọ̀ ìṣe jù yìí máa ń fi àyè bí nǹkan méjì tí a fi ń wé ara ti rí hàn. Bí àpẹẹrẹ:

(v) Ìfẹ́ ọkàn sàn *ju* ìfẹ́ ojú lọ

(vi) *Adé ga ju* Òlú lọ.

(vii) Ọmọ dára *ju* owó lọ

Atọ́ka míràn ni ***Tó***

(vii) Ó fẹ́rẹ̀ ga *tó* òpó iná

(viii) Owó kò *tó* ọmọ

(ix)Olú ga *tó* Adé ní ìwọ̀n ẹsẹ̀ bàtà márùn ún.

Àwọn wúnrẹ̀n tí a kọ yàtọ̀ ní o dúró gẹ́gẹ́ bí atọ́kùn fún àfiwé yìí. Ìtumọ̀ tí atọ́kùn àfiwé tààrà máa ń ní ni:

Jù - wa fún nǹkan méjì, níbi tí ọ̀kan ti ju èkejì lọ

Tó – wà fún nǹkan tó rí bákan náà ṣùgbọn tí kò ju ara lọ

### 8.5.2 Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́/Mẹ́táfọ̀

Irú àfiwé yìí kì í ni àwọn atọ́kùn bí àfiwé tààrà. Àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ tàbí mẹ́táfọ̀ pé oríṣiríṣi bákan náà. A rí ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀, awẹ́ gbólóhùn tàbí odidi gbólóhùn. A ó ṣe àlàyé wọn lọ́kọ̀ọ̀kan.

### (1) Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́ tàbí Mẹ́táfọ̀ ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀

Irú ẹyọ ọ̀rọ̀ wọ̀nyí lè jẹ́ ìnagijẹ tàbí àlàjẹ́. Bí àpẹẹrẹ, ebòlò, iwin, akadá, ẹlẹ́dẹ̀, jagunlabí, ajá, ẹ̀gà. Irú àwọn ìnagijẹ báyìí, mọ́tí mọ́tí bí ewé tii mọ́rí ní wọ́n máa ń rí. Bí àpẹẹrẹ, tí a bá pe ẹnìkan ní ajá, ó lè túmọ̀ sí: (i) Oníṣekúṣe (ii) Oníkanra

### (2) Àfiwẹ́ Ẹlẹ́lọ̀ọ́ tàbí Mẹ́táfọ̀ tó jẹ́ Awẹ́ gbólóhùn

Irú àfiwé yìí kì í ní atọ́kùn tàbí atọ́ka àfiwé. Àfiwé yìí sábà máa ń jẹ ọ̀rọ̀ orúkọ àti ẹ̀yán rẹ̀:

Ọ̀rọ̀ ọlọ́gbọ́n
Ọ̀rọ̀ ọmọdé
Ìtì ọ̀gẹ̀dẹ̀
Adágún odò

A fi *Ọ̀rọ̀ ọlọgbọ́n* wé ọ́rọ́ tó ní ìtumọ̀ tàbí tó ní ọgbọ́n nínú àti *ọ́rọ́ ọmọdé* wé ọ̀rọ̀ tí kò fi bẹ́ẹ̀ ní ìtumọ tàbí mú ọgbọ́n lọ́wọ́.

*Ìtì ọ́gẹ̀dẹ̀* wé ọ̀rọ̀ tàbí nǹkan tí kò ṣòro

*Adágún odò* wé ẹni tí kò lọ síwàjú tàbí padà sẹ́yìn, tó wà lójú kan, kò ní ìlọsíwájú kankan.

**(3) Àfiwé Ẹlẹ́lọ̀ọ́ tàbí Mẹ́táfọ̀ tó jẹ́ Odidi Gbólóhùn pẹ̀lú atọ́kùn 'ni' àti 'di'**

A ṣe àkíyèsí pé ọ̀rọ̀ ìṣe máa ń wà nínú àfiwé yìí nítorí pé àwọn mẹ́táfọ̀ yìí jẹ́ odidi gbólóhùn, ọ̀rọ̀ yìí, irú èyí tó wù kó jẹ́ ló ń ṣe iṣẹ́ Mẹ́táfọ̀ nínú àwọn gbólóhùn wọ̀nyí. Bí àpẹẹrẹ:

(1) Ìyá *ni* wúrà, baba *ni* dígí
(2) Ẹfúnṣetán *di* iná kò ṣe é fi sórí òrùlé sùn

Ohun tó ń fi irúfẹ́ mẹ́táfọ̀ yìí hàn ni atọ́kùn *ni* àti *di*, bí o ti ṣe àkíyèsí nínú àwọn àpẹẹrẹ òkè yìí.

**Ìwúlò Àfiwé**

1. Ó ń fi àtinúdá akéwì hàn

2. Ó ń jẹ́ kí ewì dùn létí

3. Ó ń yàwòrán àwọn nńkan ti a ò lóye tàbí ní ìrírí rẹ̀ tẹ́lẹ̀ sí ni lọ́kàn.

**8.6 Ìsọhundènìyàn**

Àbùdá yí jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí àwọn oníṣẹ́ ọnà ń ṣe àmúlò pàápàá, nínú ewì alohùn bí i ẹsẹ-ifá àti ọfọ̀ àyájọ́. Èyí ni ki wọ́n ṣe àmúlò nǹkan tí kò lẹ́mìí láti hùwà bí ènìyàn tàbí kí ó máa ṣe àwọn nǹkan tí a mọ pé ènìyàn nìkan ló jẹ mọ́. Ó máa ń fún àwọn oníṣẹ́ ọnà láàyè láti sọ èrò ọkàn wọn lórí ohunkóhun láì tọ́ka sí ẹnìkan pàtó. Bákan náà, àbùdá yi ń jẹ́ kí a lè fi ìmọ̀sílára ènìyàn sí àwọn nǹkan míràn tí ó wà ni àyíká wa tí kì í ṣe ènìyàn, yálà wọ́n jẹ́ ohun ẹlẹ́mìí tàbí èyí tí kò lẹ́mìí, èyí tí a rí tàbí tí a kò rí, kí àlàyé yìí lè yé ọ dáadáa. Bí àpẹẹrẹ:

*Òtítọ́* dọ́jà o kùtà
*Owó* Adéọlá yarọ sí báńkì
*Káràbà* ó túnra mú, odò ń gbárère
Ìgbà ojú fọ́ *àlááfíà* ń jọ̀gá

Àwọn ọ̀rọ̀ tí a kọ yàtọ̀ ni wọ́n lò gẹ́gẹ́ bí ohun abẹ̀mí tó ń ṣe ohun tí a mọ̀ pé ènìyàn lò lè ṣe é.

A lo: *Ọ̀títọ́* gẹ́gẹ́ bí nǹkan tí a gbé dọ́jà, ṣùgbọ́n tí wọn ò rẹ́ni yọwó lé e.

*Òwó* bí èeyàn tó yarọ tí kò le è kúrò lójú kan.

*Àràbà* gẹ́gẹ́ bí èèyàn to yẹ láti túnra mú tàbí tú ìwà ara rẹ̀ ṣe.

*Àlááfìà* gẹ́gẹ́ bí èèyàn kan tó ṣe pàtàkì ju ẹlòmíràn lọ.

**Ìwúlò Ìsọhundènìyàn**

1. Ó ń jẹ́ kí a gbé ìhùwàsí, ìrísí àti ìrírí ènìyàn wọ ohun tí kì í ṣe ènìyàn

2. Ó máa ń fún àwọn oníṣẹ́ ọnà láàyè láti sọ èrò ọkàn wọn lórí ohunkóhun láì tọ́ka sí ẹnìkan pàtó

3. Ó ń fi oníṣẹ́ ọnà tàbí akéwì hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ní àròjinlẹ̀.

## 8.7 Àsọrégèé

Ó jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àbùdá ti oníṣẹ́-ọnà ń ṣàmúlò láti dásọ ró iṣẹ́ ọnà wọn. Èyí ni kí oníṣẹ́ ọnà lo ọ̀rọ̀ tàbí awẹ́ gbólóhùn láti fi sọ àsọdùn tàbí àsọrégèé nípa àlàyé tàbí àpèjúwe ohun ẹlẹ́mìí tàbí ohun tí kò lẹ́mìí pẹ̀lú àwọn àbùdá tó tayọ òye irú nǹkan bẹ́ẹ̀, bí a ti mọ̀ ọ́n si tàbí ohun tí a mọ̀ ọ́n mọ́. Bí àpẹẹrẹ:

(a) Aya tó bá mojú ẹni, a le yọjú fún jẹ

(b) Bí ó tí ń forí bímọ, ló ń fìdí bí

(d)Gbogbo ayé ló ń yòmbó ilé tuntun tí Adé ṣẹ̀ṣẹ̀ kọ́.

Àpẹẹrẹ kìíní jẹ́ àsọrégèé nítorí pé ènìyàn kò lè yọ ojú rẹ̀ fún aya. (a) Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé ó ń fi irú ìfẹ́ tí ọkọ lè fihàn sí ìyàwó tó bá hùwà dáradára síi hàn. (b) Kò ṣeéṣe láti fi orí bímọ, fi ìdí bímọ. Àsọrégèé ni. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni bí ẹnìkan ṣe bímọ́ púpọ̀, nígbà tí (d) Àsọrégèé tàbí àsọdùn ni pé gbogbo ayé ló ń yòmbó ilé tuntun tí Adé ṣẹ̀ṣẹ́ kọ́, kò ṣeéṣe. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé àwọn èèyàn ń kan sáárá fún ilé tí Adé kọ́. Tún wo àpẹẹrẹ yìí láti Ìrìnkèrindò Nínú Igbó Elégbèje (1954):

(e). *Mo sín gbẹ́rẹ́ sí orí ahọ́n, mo sín sí ìdí, mo sín sí párì ẹ̀rẹ̀kẹ́, mo sín sí àtẹ́lẹwọ́, mo sín sí àtẹ́lẹsẹ̀, mo sín sí orí ọmú, mo sín sí ìdodo, mo sín sí ihò imú, mo sín sí ojú ìlà àtẹ́lẹwọ́ mi.* (pp 18-19)

Àpẹẹrẹ yìí jẹ́ àsọrégèé nítorí a mọ̀ pé kò ṣeéṣe láti sín gbẹ́rẹ́ sí àwọn ibi tó léwu bí ìdí, orí ahọ́n, ihò imú, ojú ìlà àtẹ́lẹwọ́ abbl. Nítorí náà, Fágúnwà lo àyọlò òkè yìí, láti fi ṣàlàyé bí ìmúra sílẹ̀ Ìrínkèrindò fún ìrìn àjò tó fẹ́ lọ ṣe pọ̀ tó.

**Ìwúlò Àsọrégèé**

(a) Ó ń fi bí oníṣẹ́ ọnà tí ní àtinúdá sí hàn.

(b) Àwọn oníṣẹ́ ọnà ń lò ó láti fẹ́ ọ̀rọ̀ lójú kọjá àlà

(d) Ó ń bu ẹwà kún èdè ewì

## 8.8 Àjùmọ̀rìn Ọ̀rọ̀

Àbùdá yìí máa ń kọ́wọ̀ọ́ rìn pẹ̀lú ìbádọ́gba gbólóhùn ní. Ohun tí o ṣe pàtàkì nínú ìlò àbùdá yíì ni pé àwọn ọ̀rọ̀ tó bá ń jùmọ̀ rìn gbọ́dọ̀ wà ni ọ̀wọ́ ìtumọ̀ tàbí gírámà kan náà. Àwọn akéwì sábà máa ń lò àbùdá yìí fún ẹwà, ìwọ́hùn àti láti fi gbé èrò wọn gúnlẹ̀, wo àwọn àpẹẹrẹ yìí:

K'<u>ọlọ́gbọ́n</u> f<u>etísílẹ̀</u> s'<u>ọ̀rọ̀ mi</u>
K'<u>ọ́mọ̀ràn</u> <u>tẹ́ríkodò</u> s'<u>édè</u>

O ó ṣe àkíyèsí pé àwọn ọ̀rọ̀ kan jọ rìn papọ̀ nínú àyọlò òkè yìí. Ipò tàbí ààyè kan-náà ni àwọn ọ̀rọ̀ tó jùmọ̀ rìn ti máa ń jẹyọ nínú ìhun gírámà gbólóhùn tó fi àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ hàn. 'Ọlọ́gbọ́n' bá 'Ọ̀mọ̀ràn' rìn, 'fetísílẹ̀' ba 'tẹ́ríkodò' àti ọ̀rọ̀ bá èdè rìn. Tún wo àpẹẹrẹ yìí:

Ìlàjú <u>àdúgbò</u> tí s'Ọba <u>dítìlẹ</u>'lú
Ìlàjú <u>ilé</u> tí sọ baálé d'<u>àgbélẹ̀he</u>

Ṣàkíyèsí àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ nínú àyọlò òkè 'Àdúgbò àti ilé', ọba àti baálé àti 'ìtìlẹ̀' àti 'àgbélẹ̀he dìjọ rìn pọ̀.

Ṣùgbọ́n ṣá, kì í ṣe dandan kí àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ wáyé nínú gbólóhùn onílà méjì. Ó lè wáyé nínú ìlà kọ̀ọ̀kan. Àpẹẹrẹ:

<u>Abiyamọ</u> lọ̀tá <u>àgàn</u>
<u>Alágbára</u> lọ̀tá <u>ọ̀lẹ</u>

O ó ri pé nínú gbólóhùn kan ni a tí rí àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n jùmọ̀ rìn papọ̀. *'Abiyamọ'* bá '*àgàn'*, nígbà tí *'Alágbára'* bá *'Ọ̀lẹ'* rìn papọ̀. Tún wo àpẹẹrẹ míràn:

Wọ́n ńsẹ́gun <u>ọ̀tá</u> níwá
Wọ́n ń sẹ́gun <u>odì</u> lósì

Nínú àyọlò yìí, *'ọ̀tá'* bá *'odì'* rin, nígbà tí *níwá'* bá *'lósì'* rìn. Ohun tí a ṣe àkíyèsí ni pé, irú àwọn ọ̀rọ̀ tó bá jùmọ̀ rìn gbọdọ̀ wà ni ọ̀wọ́ ìtumọ̀ kan náà tàbí gírámà kan-náà bí ó tí rí ni àwọn àpẹẹrẹ òkè wọ̀nyí.

Nígbà míràn, àwọn ọ̀rọ̀ tí wọ́n jùmọ̀ rìn lè wà ní ọ̀wọ́ ìtumọ̀ kan-náà tàbí kí wọn ní ìyísódì ìtumọ̀ ni tààrà. Ṣùgbọ́n ọ̀gangan-ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọ́n ti jẹyọ ló ń sọ wọ́n dí ìyísódì ara wọn. Bí àpẹẹrẹ

Ohun tí a wá lọ sí *sókótó*, wà ní àpò *sòkòtò*

Ọ̀gangan-ìṣẹ̀lẹ̀ ni o sọ *sókótó* di ìyísódì *sòkòtò*.

Ẹ̀wẹ̀, ìfohùngbohùn tún máa ń jẹyọ nínú àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀ bí àpẹẹrẹ:

Wọ́n ni ó beégún ilé
Ó beégún ilé
Wọ́n ní ó bòòṣà ọjà
Ó bòòṣà ọjà

O ó ṣe àkíyèsí nínú àyọlò òkè yìí bí àwọn ohùn ṣe gbé ara wọn nínú àwọn ọ̀rọ̀ tó rìn papọ̀. Ìyẹn ni pé, eégún ilé tó jẹ́ àmìn: àárín + òkè + òkè + àárín + òkè fi àmìn tó wà lórí, Òòṣà ọjà = àmìn: ìsàlẹ̀ + ìsàlẹ̀ + ìsàlẹ̀ + àárín + ìsàlẹ̀ gbé ara rẹ̀. Ṣùgbọ́n èyí kò pọn dandan fún ọ̀rọ̀ tí wọ́n jùmọ̀ rìn fi ohun ara gbe ara wọn.

**Ìwúlò Àjùmọ̀rín ọ̀rọ̀**

(1) Ó bu ẹwà kún ewì nígbà tí akéwì bá fi oríṣiríṣi ọ̀rọ̀ gbé ara wọn,

(2) Ewì tí ọnà èdè yìí bá ti wà kì í tètè sú èèyàn láti gbọ́ tàbí kà.

(3) Àbùdá yìí tún dàbí ìsọ̀yé fún àwọn akéwì.

## 9.0 Ìsọníṣókí

Ní módù yìí, o rí i kà pé èdè ojoojúmọ́ jẹ́ gbogbogbòò nígbà tí èdè ewì jẹ́ èyí tó wà fún lítíréṣọ̀, yálà ewì, ìtan-àròsọ tàbí eré-oníṣe. Bákan náà ni a rí i pé èdè ewì ń yapa sí èdè ojoojúmọ́. Àwọn ìyapa tí ó lè wáyé ni ìyapa oníròó, ẹlẹ́yọ ọ̀rọ̀, gírámà àti ìyapa onítumọ̀. A lè sọ pé nínú ládùgbó èdè ojoojúmọ́ ni èdè ewì tí ń bùwẹ̀, bùmu. Nígbà ti a ba ń sọ̀rọ̀ nípa ọnà-èdè, èdè wọ́n súnmọ́ ara wọn pẹ́kípẹ́kí, àṣepọ̀ tó wà láàrín wọn jẹ́ àtinúhùmọ̀. Àwọn àbùdá bi *Àwítúnwí, Ìbádọ́gba gbólóhùn, Ìfọ̀rọ̀dárà, Àfiwé, Ìsohùndènìyàn, Àjùmọ̀rìn ọ̀rọ̀,* àti *Àsọrégèé* ń ran àgbọ́yé àti àsọyé lọ́wọ́, wọ́n sì ń bu ẹwà kún ewì àti iṣẹ́ ọnà èyíkéyìí tí ó ń ṣe àmúlò wọn.

## 10.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kín ni èdè ojoojúmọ́, kín sì ni èdè ewì?

2. Ṣàlàyé àwọn ọ̀nà tí èdè ewì gbà ń yapa sí èdè ojoojúmọ́ àti ìwúlò tí ìyapa ní fún lítíréṣọ̀.

3. Ka ewì Adárúdurùdu nínú Àádọ́ta Àròfọ̀ ti Afọlábí Ọlábímtan (1969:5), kí ó tọ́ka sí àwọn àbùdá ọnà èdè tí ó wà níbẹ̀.

4. Ṣàlàyé ṣókí lórí ọ̀kan nínú ọnà-èdè wọ̀nyí:

   (i) Àwítúnwí

   (ii) Ìfọ̀rọ̀dárà.

## 11.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Abimbọla, W. (1970). *Ifá: An exposition of Ifá literary corpous.* Ìbàdàn: OUP.

Ajuwọn, B. (1972). *Ìjìnlẹ̀ ohùn ẹnu ifá, apá kìíní*. Ìbàdàn: Oníbọnje Press.

Bamgbose, A. (1976). *A Short Yorùbá grammar*. Ìbàdàn: Heineman Educational Books.

Chomsky, N. (1970). Current Issues in Linguistic theory, Mouton. The Hague.

Chysenor, A. (1976). *Introduction to literary stylistics*. London: B.T. Bastford Press Ltd.

Falade, M. (2021). Linguistic Ambiguity in Yorùbá Poetic Discourse. Ph. D Thesis, University of Ibadan.

Gurrey, P. (1968). *The appreciation of poetry.* London: Oxford University Press.

Hartman, R. and Stock, F. (1973). *A dictionary of language and linguistics*. London: Galliard Press.

Leech, G. (1969). *A linguistic guide to English Poetry*. Chicago: Longman.

Mukarovsky, J. (1970). Standard language and Poetic Language in Freeman, D.C. (ed), Linguistic and literary style, massachusett, H.R.W.

Ọlabọde, A. (1992). Metaphor and its allied troops Ph.D Thesis, University of Ibadan.

Ọlabimtan, A. (1977). *Àádọ́ta Àròfọ̀ pẹ̀lú àlàyé àti ìbéèrè*. Ìbàdàn: Macmillian Education.

Ọlábimtan, A. (1974). *Ewì Oríṣiríṣi*. London: Longman Nigeria Ltd.

Ọlátẹ́jú, A.O. (2004). Readings in advanced stylistics. (A monograph).

Ọlátẹ́jú, A.O. (2016). Language and style (-listics) in literary and routine communication – the Yorùbá examples an Inaugural lecture. Ìbàdàn: University Press Ibadan.

Ọlátúnjí, O. (2005). *Features of Yorùbá Oral Poetry*: Ìbàdàn: University Press Plc.

Ọlátúnbọ̀sún, O. (1973). *Àròyé Akéwì* Apa Kìíní. Ìbàdàn: Oníbonoje Press and Books Ltd.

Ogunyẹmi, R. (1998). *Ìmọ̀ Ìṣọwọ́lo-èdè Yorùbá*. Lekoba Publishers.

Ogunyẹmi, R. (2002). *Àtúpalẹ̀, Ìtọpínpín, Ìgbéléwọ̀n àti Ìwúlò Ajẹmẹ́wà lítíréṣọ̀ Yorùbá*. Lekoba Publishers.

Raji, S.M. (1991). *Winrínwirìn ẹnu onírárà*. Onibonoje Press and Books Ltd.

Traugott, E.C., Partt, M.L. (1984). *Linguistics for student of literature*. Harcourt Brace.

Welleck, R. and Warren, A. (1973). *Theory of Literature*. Pengium University Books.